Language: Yorùbá

**Oyè ìyálóde: ipò akọnibìnrin nínú ètò ìṣèlú àwùjọ Yorùbá**

**Remi ALAPO (PhD)**
Assistant Professor, History, Philosophy, Anthropology Department
City University of New York (CUNY), York College
E-mail: rhemy007@gmail.com
ORCID iD https://orcid.org/0000-0001-7247-0827

**ÀṢAMỌ̀**
Iṣẹ́ yìí ṣe àgbéyẹ̀wò òye Ìyálóde gẹ́gẹ́ bí ipò àṣíwájú àti ìpìlẹ̀ fún ìfẹ̀hónúhàn àwọn obìnrin Áfíríkà nínú Ìjákọni Ìṣèlú nínú ìlànà ètò ìṣèjọba ìbílẹ̀ Yorùbá. Nípa ṣíṣe àfàyọ ẹ̀rí láti inú ìmọ̀ ìtàn, tíọ́rì aṣègbèfábo Áfíríkà, èrò ìjìnlẹ̀ nípa ìṣèlú ìbílẹ̀, àṣà alohùn àti ìṣèwádìí tí ó jinlẹ̀, iṣẹ́ yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé Ìyálóde dúró gẹ́gẹ́ ọ̀kan nínú ipò tí ó ní ààtò, ìfaradà àwòṣe tí ó gbajúgbajà láàrin àwùjọ nínú àwọn ipò obìnrin nínú agbára ìṣèlú Áfíríkà. Dípò kíkópa ajẹmayẹyẹ tàbí àmì oyè lásán, Ìyálóde ní ààtò tí ó ṣodo sínú ipò ìṣèlú nípasẹ̀ èyí tí èrò àwọn obìnrin, agbára àwùjọ, àti agbára ìjẹmáṣojú ti máa ń wáyé nínú ìlànà ìṣèjọba Yorùbá. Gbígbé Ìyálóde sí ọ̀gangan ipò ẹ̀kọ́ ìmọ̀ ajẹmọ́-adarí Áfíríkà lápapọ̀, iṣẹ́ yìí ṣe àtúngbékalẹ̀ ìjákọni gẹ́gẹ́ bí àṣà àti ìwà ìmẹ̀tọ́ èyí tí ó jẹ yọ nínú ìfarasìn, àkóyawọ́ àti ìtẹ̀ṣíwájú láti ìran dé ìran, dípò ìdánìkànṣe tàbí ìṣagbára mọ́ ogun. Ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ yìí tọpinpin ìtàn ìpìlẹ̀ oyè Ìyálóde káàkiri ilẹ̀ Yorùbá, ó ṣe àgbéyẹ̀wò bí ààtò agbára àwọn obìnrin nínú ìṣèlú ṣe wáyé nínú ìpínká ìlànà ìṣèjọba ṣáájú ìmúnisìn àti ìmúdúró rẹ̀ lẹ́yìn ìdàrúdàpọ̀ ìmúnisìn. Nípa wíwo Ìyálóde gẹ́gẹ́ bí oyè ìbílẹ̀ àti ipò adarí òde-òní, iṣẹ́ yìí ṣe àfikún sí ìtako ìmúnisìn, àti ìmọ̀ lórí aṣègbèfábo Áfíríkà, ó jẹ́ ìpèníjà fún ìmọ̀ ìtàn ajẹmọ́-jẹ́ńdà àti ìmúnisìn nípa ètò ìṣèjọba Áfíríkà, ó sì gbé Ìyálóde kalẹ̀ gẹ́gẹ́ bí àwòṣe tí ó ní agbára nípa Ìjákọni Ìṣèlú àwọn obìnrin Áfíríkà pẹ̀lú wíwo pàtàkì rẹ̀ nínú ìjíròrò nípa ipò adarí, ìṣẹ́tọ́ jẹ́ńdà àti àṣà ajẹmọ́-òmìnira.

**KOKO-ỌRỌ**:
Ìṣètọ́fabo Áfíríkà, Ìjákọni Obìnrin Áfíríkà, Ìtẹ̀ṣíwájú ajẹmáṣà, ìṣèjọba ìbílẹ̀, Ìyálóde, Ogbomoso, Agbára Ìṣèlú, Adarí obìnrin Yorùbá

**Oyé yáylóde: o papel da heroína na sociedade política iorubá**

**RESUMO**
Este trabalho examina a compreensão de Iyalóde como uma posição de liderança e uma base para a representação das mulheres africanas no poder político dentro da estrutura da governança tradicional iorubá. Recorrendo a evidências do conhecimento histórico, da teoria política africana, do pensamento político tradicional, da tradição oral e de pesquisa aprofundada, este trabalho estabelece que Iyalóde se destaca como um dos modelos mais duradouros, relevantes e socialmente relevantes das posições das mulheres no poder político africano. Mais do que um mero símbolo cerimonial, Iyalóde é um ritual inserido no contexto político por meio do qual as ideias das mulheres, o poder social e o poder de representação são incorporados na

governança iorubá. Colocando Iyalóde na vanguarda da ciência política africana, este trabalho restabelece a liderança como uma cultura e uma virtude que emerge da submissão, da cooperação e do progresso de geração em geração, em vez do individualismo ou da força militar. Este estudo traça as origens históricas do título de Iyalóde na Iorubalândia, examinando como a prática do poder político feminino foi moldada pela fragmentação da governança pré-colonial e sua consolidação após a ruptura colonial. Ao analisar Iyalóde como um título tradicional e uma posição de liderança contemporânea, este estudo contribui para o debate sobre o colonialismo e para a ciência política africana, desafia a compreensão histórica de gênero e colonialismo na política africana e apresenta Iyalóde como um modelo poderoso de liderança política feminina africana, com foco em sua importância nas discussões sobre governança, igualdade de gênero e cultura de libertação.

**PALAVRAS-CHAVE**
Herança Africana, Liderança Feminina Africana, Avanço Tradicional, Governança Tradicional, Maternidade, Ogbomoso, Poder Político, Líderes Femininas Iorubás

## Oyé yáylóde: le rôle de l'héroïne dans la société politique yoruba

**RÉSUMÉ**

Ce travail examine la notion d'Iyalóde comme position de premier plan et fondement de la représentation des femmes africaines au sein du pouvoir politique dans le cadre de la gouvernance traditionnelle yoruba. S'appuyant sur des données issues de la connaissance historique, de la théorie politique africaine, de la pensée politique traditionnelle, de la tradition orale et d'une recherche approfondie, ce travail établit que l'Iyalóde constitue l'un des modèles les plus pérennes, pertinents et socialement durables de la place des femmes dans le pouvoir politique africain. Bien plus qu'un simple symbole cérémoniel, l'Iyalóde est un rituel ancré dans le contexte politique, à travers lequel les idées, le pouvoir social et le pouvoir de représentation des femmes s'incarnent dans la gouvernance yoruba. En plaçant l'Iyalóde au cœur de la science politique africaine, ce travail réaffirme le leadership comme une culture et une vertu qui émergent de la soumission, de la coopération et du progrès de génération en génération, plutôt que de l'individualisme ou de la force militaire. Cette étude retrace les origines historiques du titre d'Iyalóde au pays Yoruba, en examinant comment l'exercice du pouvoir politique féminin a été façonné par la fragmentation de la gouvernance précoloniale et sa consolidation après la décolonisation. En analysant l'Iyalóde comme titre traditionnel et position de leadership contemporaine, cette étude contribue au débat sur le colonialisme et à la science politique africaine, remet en question la compréhension historique du genre et du colonialisme dans le système politique africain et présente l'Iyalóde comme un modèle puissant de leadership politique féminin africain, en soulignant son importance dans les discussions sur la gouvernance, l'égalité des genres et la culture de la libération.

**MOTS-CLES**
Patrimoine africain, Leadership féminin africain, Promotion traditionnelle, Gouvernance traditionnelle, Maternité, Ogbomoso, Pouvoir politique, Femmes dirigeantes yoruba

**Ìfáàrà**

Ohun tí ọ̀pọ̀ ìtàn tí ó wà nípa ètò ìṣèlú ilẹ̀ Adúláwọ̀ tọ́ka sí fi hàn pé ipa àwọn obìnrin kò fojú hànde tó nínú òṣèlú, èyí ó fi hàn pé ipò ẹ̀yìn ni àwọn obìnrin wà nínú ètò ìṣàkóṣo àwùjọ wọn. Ìtàn irú bẹ́ẹ̀ ti mú kí ọ̀pọ̀ ènìyàn ro pé ìṣàkóso, agbára ìdarí àti ipò olórí jẹ́ ohun tí ó jẹ́ ogún ìní àwọn akọnìyàn nìkan. Èrò nípa yìí gbára lé ìpìlẹ̀ ètò akọ̀lólori tí ìjọba amúnisin mú wọ àwùjọ Adúláwọ̀, nítorí pé wọ́n mú ìpààlà sáàrin ẹ̀tọ́ akọ àti abo ti ilẹ̀ Aláwọ̀-funfun, ìlànà ìṣèjọba ìṣàkóso tí ó dojukọ́ ààrín kan ṣoṣo àti ìlànà akọ̀lólori wọ àwùjọ Adúláwọ̀, léyìí tí ó sì jẹ́ pé wọ́n ní ìlànà ètò ìṣèlú tíwọn tẹ́lẹ̀ (Oyewumi, 1997; Amadiume, 1997). Fún ìdí yìí, ọ̀pọ̀ àṣìsọ ni ó ń wáyé nípa ètò ìṣèlú ìbílẹ̀ Adúláwọ̀, tí ipa ìdarí àwọn obìnrin sì di ohun tí kò fojú hànde tààrà mọ́ tàbí tí kì í ṣe nǹkan pàtàkì (Awe, 1992; Ranger, 1983).

Ní ìdàkejì, ètò ìṣàkóso ìbílẹ̀ Yorùbá fi hàn pé àwọn obìnrin ní ipò àti ipa ìdarí tí ó fojú hànde nínu akitiyan ètò ìṣèlú. Ìmọ̀ ìtàn àti ẹ̀kọ́ nipa àṣà ènìyàn fi hàn pé ètò ìṣàkóso Yorùbá dá lórí pínpín agbára, ìpinnu pẹ̀lú ìgbìmọ̀ àti ìdọ́gba agbára láàrin ọba, àwọn ìjòyè, àwọn àgbà ìdílé, àti àwọn aṣojú ilé-ìṣẹ́ àwùjọ (Fálọlá, 1999; Peel, 2000). Nínú irúfẹ́ ètò báyìí, ipa ìdarí àwọn obìnrin kì í ṣe ohun kàyééfì tàbí ohun tí ó mòòkùn; dipo bẹ́ẹ̀, ó wà gẹ́gẹ́ bí apá kan ti ètò ìṣàkóso, nípasẹ̀ àwọn ipò ìṣèlú pa agbára, tí ó sì ní ojúṣe àti agbára láti kópa nínú ìpinnu ìlú (Awe, 1992).

Ọ̀kan pàtàkì tí ó tayọ nínú àwọn ipò obìnrin ni ipò Ìyálóde, èyí tí ó jẹ́ ipò ìṣèlú tí ó ga jù lọ tí obìnrin lè dì mú ní ọ̀pọ̀ ìlú ní Yorùbá. Láti ìgbà àtijọ́ títí di òní, ipò Ìyálóde kì í ṣe ipò ayẹyẹ tàbí àfihàn lasan. Ó jẹ́ aṣojú gidi fún àwọn obìnrin nínú ètò ìṣèlú ìlú. Ó tún jẹ́ ipò tí ó ní ọ̀wọ̀ àti àpọ́nlé nínú ìgbìmọ̀ ìṣàkóso ìlú. Ó dúró gẹ́gẹ́ bí alárinà láàrin ọ̀wọ́ àwọn obìnrin àti àwọn alákóso ìlú. Agbára ipò yìí sáábà máa ń dá lórí ìtẹ̀síwájú ọjọ́-ori, ìtẹ́wọ́gbà ìdílé, ìwà rere, àti iṣẹ́ tí ẹni náà ti ṣe fún ìdàgbàsókè ìlú. Àwọn ìlànà wọ̀nyí fara mọ́ ìmọ̀ òṣèlú Yorùbá, tí ó máa ń fi ìdọ́gba, ojúṣe, àti ìbáṣepọ̀ àwùjọ síwájú ju lílo agbára tàbí ipa lọ (Oyewumi, 1997; Wiredu, 1996).

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ipò Ìyálóde ṣe pàtàkì nínú ètò ìṣèjọba ní àwùjọ Yorùbá, síbẹ̀, kò àkíyèsí tó gbòòrò nínú ọ̀pọ̀ iṣẹ́ tí ó ti wà nípa ètò ìṣèlú àti ìtàn ìṣàkóso, pàápàá jù lọ, nínú ẹ̀ka ìwádìí tí ń ṣe àfiwé ìlànà ìdarí lóníran-ì-ran. Nígbà tí a bá mẹ́nuba agbára òṣèlú àwọn obìnrin ní Adúláwọ̀, ọ̀pọ̀ ìgbà ni a máa ń ṣàlàyé rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ohun tí kò wọ́pọ̀ tàbí ohun tí ó ṣẹlẹ̀ nígbà ìjà tàbí ìfarapa àwùjọ. Irú ìtúpalẹ̀ bẹ́ẹ̀ máa ń fi ipa ìdarí àwọn obìnrin pamọ́, ó sì tún ń mú èrò amúnisin lagbara pé agbára òṣèlú jẹ́ ohun tí ó jẹ́ ti ọkùnrin àti ti ìjọba ààrín kan ṣoṣo (Vaughan, 2000).

Ìṣègbèfábo ilẹ̀ Adúláwọ̀ ti ṣe ipa pàtàkì nínú fífi dojú kọ irú ìtumọ̀ bẹ́ẹ̀. Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ nínú ẹ̀ka yìí sọ pé a gbọ́dọ̀ lóye ipa àti agbára àwọn obìnrin Adúláwọ̀ láti inú ìmọ̀ àti àṣà ilẹ̀ Adúláwọ̀ fúnra rẹ̀. Wọ́n tún jiyàn pé nínú ọ̀pọ̀ àwùjọ ilẹ̀ Adúláwọ̀, ipa ènìyàn nínú àwùjọ máa ń dá lórí ipo àwùjọ, ọjọ́-ori, àti ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn mìíràn, kì í ṣe lórí ìyàtọ̀ akọ àti abo gẹ́gẹ́ bí a ṣe máa ń rí i nínú ìmọ̀ àwọn Òyìnbó Aláwọ̀-funfun (Ògúndípẹ̀-Leslie, 1994; Oyewumi, 1997; Nzegwu, 2006). Bákan náà, ipò Ìyálóde kì í ṣe ohun àjèjì nínú ètò ìṣàkóso

Yorùbá, ó jẹ́ abajade tí ó bófin mu láti inú ìmọ̀ ìṣèlú àwọn ẹ̀yà Yorùbá àti ètò ìṣàkóso ìbílẹ̀ wọn.

Àfojúsùn iṣẹ́ ìwádìí ni ìtúpalẹ̀ ìtàn àti ìmò ìṣáájú nípa fífi ipò Ìyálóde hàn gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára àwọn òpó pàtàkì nínú ìkópa àwọn obìnrin nínú ètò ìṣèlú àwùjọ Yorùbá àti ilẹ̀ Adúláwọ̀. Iṣẹ́ yìí wí àwíjàre nípa pé ipò Ìyálóde jẹ́ àpẹẹrẹ ipò akíkanjú òṣèlú fún àwọn obìnrin Adúláwọ̀ èyí tí kò gbára lé àbùdá àbímọ́ àwọn aboniyàn nípa ìlò agbára àfojúrí; ṣùgbọ́n, ó dá lórí ìtẹ̀síwájú ipò, ìṣàkóso pẹ̀lú ìwà rere àti aṣojú gbogbo àwọn obìnrin nínú àwùjọ. Bí a bá wo ìtumọ̀ "akíkanjú" nípa ìmọ̀ ilẹ̀ Adúláwọ̀, ìwádìí yìí fi hàn pé ó ju ìlò agbára àfojúrí, èyí tí ó ń jẹ yọ nínú ètò ìṣèlú nìkan lọ (Achebe, 1984 Mbembe, 2001). Ìwádìí yìí ní àfojúsùn mẹ́ta tí wọ́n jọ ní ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú ara wọn:

Àkọ́kọ́, ó ṣe àgbéyẹ̀wò ìpìlẹ̀ ìtàn, ìtumọ̀, ipò àti ojúṣe Ìyálóde nínú ètò ìṣèjọba ní ilẹ̀ Yorùbá, tí ó sì fi ipò náà ṣe àwòta àṣà Adúláwọ̀ nípa agbára ìwà rere àti ojúṣe Ìyálóde nínú òṣèlú.

Ẹlẹ́ẹ̀kejì, ó tọpinpin ìfarahàn ipò Ìyálóde káàkiri ilẹ̀ Yorùbá, láti fi hàn pé agbára àwọn obìnrin nínú ètò ìṣèlú wà gẹ́gẹ́ bí òpó kan ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ agbègbè, láìkan ìyípadà tí ìjọba amúnisin mú wọ àwùjọ Adúláwọ̀ (Law, 1977; Afigbo, 1972).

Ẹ̀kẹta, ó ṣe àgbéyẹ̀wò bí ipò Ìyálóde ṣe ṣe pàtàkì tó ní ayé òde-òní, nípa fífi Ìyálóde ti Ilẹ̀ Ògbómọ̀ṣọ́ tí ó wà lórí oyè báyìí ṣe àwòta, láti fi hàn bí ìdarí àwọn obìnrin nínú àṣà ìbílẹ̀ ṣe ń ṣiṣẹ́ gẹ́gẹ́ bí apá kan nínú ètò ìṣèjọba àti ìṣàkóso ìlú títí di òdé-òní yìí.

Nípa fífi Ìyálóde ṣe àfojúsùn ìtúpalẹ̀ gẹ́gẹ́ bí òpó kan nínú ètò ìṣèjọba ní òde-òní, iṣẹ́ yìí ń ṣe àfikún sí ìmọ̀ ìṣègbèfábo Adúláwọ̀, nípa mímú èrò àwọn amúnisin kúrò nínú ìtàn àti ìmọ̀ nípa ìṣàkóso ilẹ̀ Adúláwọ̀. Ó tún ń mú agbára ìṣèlú àwọn obìnrin Adúláwọ̀ padà sínú ìmọ̀ ìtàn. Iṣẹ́ yìí dojú kọ àwọn èrò ìmọ̀ tí ń dín ipa àti ètò ìṣàkóso ìbílẹ̀ kù, ó sì ń fi hàn pé àwọn obìnrin Adúláwọ̀ jẹ́ alábòójútó ètò ìṣèlú àti ìṣèjọba pẹ̀lú ìwà rere. Ní ìbámu pẹ̀lú àfojúsùn àti àbùdá àwọn akọnikùnrin àti akọnibìnrin ilẹ̀ Adúláwọ̀, ìwádìí yìí fi Ìyálóde hàn gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ àwọn obìnrin tí ó jẹ́ akíkanjú nínú ìṣèlú ilẹ̀ Adúláwọ̀, tí agbára rẹ̀ dá lórí ìtẹ̀síwájú, ìránṣẹ́ àwùjọ àti ìtẹ̀síwájú àṣà ju ìtàn ìgbésí ayé ẹni kọ̀ọkan lọ (Tamale, 2020).

Àwọn iṣẹ́ ìṣáájú nípa ètò ìṣèlú Yorùbá, agbára ìṣèlú àwọn obìnrin Adúláwọ̀ àti ètò ìṣèjọba ìbílẹ̀ jẹ́ ìpìlẹ̀ pàtàkì fún ìtúpalẹ̀ àwọn ohun tí ó jẹ mọ́ ipò Ìyálóde nínú ètò ìṣèlú. Àwọn ìwádìí wọ̀nyí jẹ yọ láti inú ẹ̀ka ìmọ̀ ní oríṣìíríṣìí bí ìmò ìtàn, ìmọ̀ àwùjọ-àdáyébá (anthropology), aṣègbèfábo àti ìmọ̀ ìṣàtakò amúnisin. Àfojúsùn gbogbo wọn ni èrò nípa pé agbára ìṣèlú nínú àwùjọ ilẹ̀ Adúláwọ̀ jẹ́ ohun tí ó ṣe ìgbéyọṣíwájú ọkùnrin nìkan tàbí ohun tí ó dá lórí ìjọba ọ̀wọ́ àárín kan ṣoṣo. Dípò bẹ́ẹ̀, àwọn aṣèwádìí àwùjọ Yorùbá àti ètò ìṣèlú ilẹ̀ Adúláwọ̀ ti fi hàn pé ètò ìṣàkóso Yorùbá dá lórí pínpín agbára, oríṣìíríṣìí agbọn ìṣàkóso àti ipa pàtàkì tí àwọn obìnrin ń kó nínú ètò ìṣàkóṣo ìlú àti ìwà rere nínú àwùjọ (Awe, 1992; Fálọlá, 1999; Peel, 2000).

Pẹ̀lú èyí, àwọn aṣèwádìí ìṣègbèfábo ilẹ̀ Adúláwọ̀ àti ìṣàtakò-ìmúnisìn ti fi hàn pé ìmọ̀ tí ìjọba amúnisin mú wá yí àlàyé àti ìtumọ̀ àwọn ètò ìṣejọba ìbílẹ̀ wọ̀nyí padà, ó sì dín ipa ìṣèjọba àwọn obìnrin kù nínú ètò ìṣàkóso ìlú àti nínú ìtàn àpilẹ̀kọ (Oyewumi, 1997; Amadiume, 1997). Nípa kíkó gbogbo àwọn ìwádìí wọ̀nyí jọ, ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ yìí fi ipò Ìyálóde sínú ìmọ̀ tí ó gbòòrò, tí ó mọ̀ pé àwọn obìnrin Adúláwọ̀ jẹ́ olórí ilé-ìṣẹ́, àwọn akíkanjú nínú òṣèlú àti alábòójútó ìṣàkóso pẹ̀lú ìwà rere láti ìgbà àtijọ́ títí di òde-òní.

**Àwọn Obìnrin àti Agbára Ìṣèlú ní Àwùjọ Yorùbá**

Ọpọ̀ ìwádìí amòye nípa àwùjọ Yorùbá ti fi hàn pé ìròyìn tí àwọn kan máa ń sọ pé ìjọba ilẹ̀ Adúláwọ̀ ṣáájú ìgbà amúnisìn kò jẹ́ kí obìnrin kópa nínú ìṣèlú kì í ṣe òtítọ́. Ìmọ̀ ìtàn, ìmọ̀ àwùjọ-àdáyébá (anthropology), àti ìmọ̀ aṣègbèfábo (feminist studies) fi hàn pé ètò ìṣèlú Yorùbá dá lórí ìpín agbára, ìṣàkóso pẹ̀lú ìgbìmọ̀, àti fífi ipò olórí fún obìnrin nínú àkóso ìlú. Dípò kí gbogbo agbára wà lọ́wọ́ ọba kan ṣoṣo tàbí pé ọkùnrin nìkan ni wọ́n ní agbára ìṣèlú, ètò ìṣèjọba Yorùbá dá lórí àjọṣe àwọn ìgbìmọ̀, àwọn olórí ìlú, àwọn àgbààgbà ìdílé àti àwọn obìnrin tí ó jẹ́ olórí. Èyí mú kí ìṣàkóso di ohun tí a máa ń ṣe pẹ̀lú ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àti ojúṣe oníkalukù.

Nínú ìlànà yìí, agbára ìṣèlú obìnrin kì í ṣe ohun tí kò jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà. Àwọn obìnrin ní ipò agbára tí a mọ̀ dá wà, wọ́n sì ní àjọ àti ipò tó jẹ́ kí wọ́n lè kópa nínú ìṣàkóso ìlú, ìdájọ́ ọ̀ràn, ìṣètò ọrọ̀ ajé àti ìpinnu lórí ìṣòro àwùjọ. Awẹ́ (1992) ṣàlàyé pé àwọn obìnrin Yorùbá ní ipa tó lágbára gan-an nínú ètò ìṣèlú, ètò ọrọ̀ ajé àti ètò ìgbé-ayé àwùjọ. Ó tún fi hàn pé ìṣètò olórí ní àwùjọ Yorùbá kì í dá lórí akọ tàbí abo nìkan, ṣùgbọ́n ó dá lórí ọjọ́-orí, ìbáṣepọ̀ ìdílé, ìwà rere, àti ìgbẹ́kẹ̀lé tí àwùjọ ní sí ẹni náà. Nítorí náà, obìnrin tí ó bá ti lọ́jọ́ lórí, tí ó sì ní ìwà rere lè di olórí láìsí ìṣòro tàbí ìtakora.

Apá kan pàtàkì nínú ipò ìṣèjọba àwọn obìnrin ni ipò Ìyálóde, èyí tí ó jẹ́ ipò obìnrin tó ga jù lọ nínú ètò ìṣèlú Yorùbá. Ìtàn láti ọ̀pọ̀ agbègbè Yorùbá bí Ọyọ́, Ìjẹ̀ṣà, Ìjẹ̀bú, Ẹ̀gbá, àti Oǹdó fi hàn pé Ìyálóde jẹ́ ẹni tí a mọ̀ gẹ́gẹ́ bí olórí ìṣèlú gidi. Agbára rẹ̀ kò mọ níbí dídá àwọn ọ̀ràn tí ó bá jẹ mọ́ obìnrin nìkan, ó tún kan ìṣàkóso ìlú, ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn ìlú mìíràn, àti ìpèsè agbára àti ìbágbépọ̀ àwùjọ. (Law, 1977; Bascom, 1969; Fálọlá 1999). Ìyálóde jẹ́ aṣojú gbogbo obìnrin nínú ìlú. Ó máa ń kópa nínú ìgbìmọ̀ àwọn olórí àti àgbàlagbà, ó sì tún máa ń ṣiṣẹ́ gẹ́gẹ́ bí alárinà nínú pípari ìjà tàbí àríyànjiyàn tí ó lè kan àlàáfíà ìlú.

Láti ìgbà pípẹ́ ni àwọn obìnrin Yorùbá tí máa ń lo agbára ìṣèlú wọn nípasẹ̀ àwọn ipò àjọṣepọ̀ gẹ́gẹ́ bí olórí ọjà, ìgbìmọ̀ ìdílé, àti àwọn ẹgbẹ́ obìnrin. Àwọn ipò wọ̀nyí jẹ́ ibi tí wọ́n ti máa ń ṣe ètò ìṣèlú, ìṣùwà-yanjú-ìṣòro àti ìpinnu. Àwọn ipò wọ̀nyí ṣiṣẹ́ pọ̀ pẹ̀lú ìṣàkóso àwọn ọkùnrin, èyí sì fi hàn pé ìṣàkóso Yorùbá jẹ́ ohun tí akọnìyàn àti abonìyàn ń kópa papọ̀ nínú rẹ̀. Èyí nip é kì í ṣe pé ẹgbẹ́ kan ṣoṣo ló ní agbára (Mba, 1982; Sudarkasa, 1986). A rí àpẹẹrẹ ọ̀pọ̀ àwọn wọ̀nyí ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìlú ní ilẹ̀ Yorùbá. Fún ìdí èyí, ìṣèjọba àwọn obìnrin jẹ́ apá kan nínú ètò ìgbé-ayé àti ìgbáyégbádùn àwọn ènìyàn àwùjọ Yorùbá. Èyí sì ní ipa lórí ètò ọrọ̀ ajé, ìlànà àwùjọ àti ìdájọ́ òdodo nínú àwùjọ wọn. Bí àwọn ipò yìí ṣe fìdí múlẹ̀ fún ọ̀pọ̀ ọdún fi hàn pé agbára ìṣèlú obìnrin Yorùbá kì í ṣe ohun tí ó ṣẹ̀ṣẹ̀ dé àarin àwùjọ. Nígbà tí ìyípadà ìṣèlú bá wáyé, gẹ́gẹ́ bí ìgbòkègbodò ètò ìṣèjọba tàbí ìyípadà agbára ní agbègbè kan, àwọn ipò obìnrin ṣì ń bá yí, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé wọ́n máa ń ṣe àtúnṣe díẹ̀ sí i (Law, 1977; Peel, 2000). Èyí fi hàn pé ìmòye ìṣèlú Yorùbá ní ìlànà ìdọ́gba, ìkópa gbogbo ènìyàn, àti ìṣàkóso pẹ̀lú ìwà rere.

Ohun tí ó fojú hàn ni pé ìṣèjọba amúnisìn (colonial rule) dá ètò ìṣètò àwùjọ Adúláwọ̀ rú ṣùgbọ́n wọn kò rí i pa run patapata. Àwọn alákóso amúnisìn fi ọkùnrin sí iwájú gẹ́gẹ́ bí aṣojú nínú ètò ìṣèlú, wọ́n sì dín ipa obìnrin kù nínú ìjọba ìbílẹ̀. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ bẹ́ẹ̀, ìtàn àtẹnudẹ́nu jẹ́ kí ipò àwọn obìnrin bíi Ìyálóde rí ìdí fi múlẹ̀ (Afigbo, 1972; Vaughan 2000). Lẹ́yìn ìjọba amúnisìn, ọ̀pọ̀ àwọn onímọ̀ ti ṣe ìhújáde àwon ìtàn wọ̀nyí, wọ́n sì fi hàn pé agbára ìṣèlú àwọn obìnrin ṣì ń jẹ yọ nínú ìbágbépọ̀, ìrántí àṣà àti ìtẹ́wọ́gbà àwọn ipò ìbílẹ̀ nínú àwùjọ Yorùbá (Amadiume, 1997; Oyèwùmí, 1997). Àwọn ìwádìí wọ̀nyí fi hàn pé

àwọn obìnrin Yorùbá ti pẹ́ gan-an tí wọ́n ti jẹ́ apá kan pàtàkì nínú ètò ìṣèlú. Wọ́n ń lo agbára wọn nípasẹ̀ àwọn ipò tí àwùjọ yá sọ́tọ̀ fún wọn, èyí tí ó níí ṣe pẹ̀lú ọjọ́-orí, ìtẹ́wọ́gbà àwùjọ àti ojúṣe fún gbogbo ènìyàn. Fún ìdí èyí, ipò Ìyálóde kì í ṣe ohun àrà ọ̀tọ̀ tàbí ohun ọ̀tun ṣùgbọ́n ó jẹ́ ìlànà ìṣèjọba àwọn obìnrin nínú ìṣàkóso àwùjọ Yorùbá, èyí tí ó ti wà fún ọ̀pọ̀ ọ̀rúndún.

**Àfiwé Ìṣàkóso Ìṣèlú àwọn Obìnrin ní Àwùjọ Adúláwọ̀**

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwùjọ Yorùbá jẹ́ ọ̀kan lára àwọn àwùjọ tí ìtàn wọn fojú hàn nípa bí wọ́n ṣe fi ipò ìṣàkóso ètò ìṣèlú fún obìnrin sílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí apákan ìlànà ètò ìṣèjọba, ìwádìí nípa àfíwé àwọn àwùjọ ilẹ̀ Adúláwọ̀ fi hàn pé ìfìdímúlẹ̀ ipò olórí fún obìnrin kì í ṣe ohun tí ó ṣọ̀wọ́n tàbí ohun tí ó jẹ́ ìlànà kan ṣoṣo. Ní ọ̀pọ̀ àwùjọ ilẹ̀ Adúláwọ̀, ṣáájú ìgbà ìjọba amúnisin, àwọn obìnrin ní agbára ìṣèlú tí àwùjọ, wọ́n sì ń lo agbára yìí nípasẹ̀ àwọn ìlànà ìṣèlú tí wọ́n yà sọ́tọ̀, tí wọ́n sì ń ṣiṣẹ́ papọ̀ pẹ̀lú ètò ìṣàkóso ọkùnrin. Àwọn àpẹẹrẹ wọ̀nyí fi hàn pé nínú ìlànà ìṣàkóso ilẹ̀ Adúláwọ̀, wọ́n máa ń pín agbára láàárín àwọn ìṣọ̀rí akọnìyàn àti abonìyàn, wọ́n ń ṣiṣẹ́ papọ̀ fún àgbágbè ara wọn.

Ní àwùjọ àwọn ẹ̀yà Igbo, ìṣàkóso ìṣèlú obìnrin fara hàn nínú ètò ìṣèlú ajẹmọ́ takọ-tabo. Nínú èyí tí àwọn ọkùnrin àti obìnrin ti ń ṣiṣẹ́ lọ́tọ̀ọ̀tọ̀, tí wọ́n sì ní ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú ara wọn. Àwọn obìnrin ń lo agbára wọn ní àpéjọ obìnrin, ìgbìmọ̀ ìdílé, àjọ ọjà àti àwọn ipò olórí bí Omu, èyí sì ń jẹ́ kí wọ́n lè ṣètò ìṣèlú ọjà, kí wọ́n parí aáwọ̀, kí wọ́n sì kó àwọn ènìyàn jọ (Mba, 1982; Nzegwu, 2006). Àwọn ìlànà wọ̀nyí ní òmìnira, kò sí ní abẹ́ ìṣàkóso àwọn ọkùnrin. Nípa báyìí, àwọn obìnrin lè lo agbára ìṣèlú wọn lọ́tọ̀, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé wọ́n tún jẹ́ apákan nínú ètò ìṣàkóso àwùjọ lapapọ̀. Bí ti Ìyálóde ṣe jẹ́ ní àwùjọ Yorùbá, ìtẹ́wọ́gbà àwọn olórí obìnrin Igbo máa ń wá nípa wíwo ọjọ́-ori, ìgbàgbọ́ àwùjọ àti àjùmọ̀ṣe gbogbo ènìyàn.

Ní ọ̀dọ̀ àwọn Akan, agbára ìṣèlú obìnrin fara hàn nínú ipò Ìyá Ọba, ipò tí wọ́n fọwọ́ sí gẹ́gẹ́ bí apákan pàtàkì nínú ètò ìṣàkóso ìbílẹ̀ wọn. Àwọn Ìyá Ọba máa ń kó ipa nínú yíyan olórí, ìpinnu ẹni tí yóò gorí ìtẹ́, ìdájọ́ àwọn ọ̀ràn dídá láàrin àwùjọ àti mímú ìlànà ìwà rere dúró. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà, wọ́n máa ń ṣiṣẹ́ pọ̀ pẹ̀lú àwọn ìjòyè gẹ́gẹ́ bí alábòójútó ìṣèlú gbogbogbò (Gyekye, 1997).

Nínú ètò ìṣèjọba àwọn ẹ̀yà Benin, àwọn obìnrin ní ipò pàtàkì nínú ètò ìṣàkóso ààfin àti ilé-ẹjọ́ ọba. Iyoba, ìyẹn Ìyá Ọba, ni aṣíwájú àwọn obìnrin nínú ètò ìṣèlú, èyí sì ti wà láti ǹǹkan bí ọrundún kẹrìnlá-dín-lógún síwájú. Ó máa ń kó ipa nínú ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn orílẹ̀-èdè mìíràn, ìṣàkóso àṣà àti ìṣe nínú èto ìṣèjọba ààfin. Ìfẹsẹ̀múlẹ̀ ipò Iyoba fi hàn pé nínú ọ̀pọ̀ àwùjọ Ìwọ̀-Oòrùn Adúláwọ̀, wọ́n ya ipò ìṣàkóso obìnrin sọ́tọ̀ gẹ́gẹ́ bí apákan nínú ètò ìṣàkóso (Sudarkasa, 1986). Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ètò ìṣàkóso ìjọba Benin kó agbára jọ sí ààrín gbùngbùn ju ti àwọn ẹ̀yà Yorùbá lọ, ṣíbẹ̀, Ìyá Ọba ní àwọn àbùdá kan tí ó jọra pẹ̀lú Ìyálóde nítorí pé agbára wọn dá lórí ọjọ́-ori, ìwà rere àti bíbá àṣà mù.

Ní ilẹ̀ Dahomey (Benin Republic), ìṣàkóso obìnrin jẹ́ apákan nínú ètò ìṣàkóso àti ètò ogun orílẹ̀-èdè náà. Àwọn obìnrin ṣiṣẹ́ gẹ́gẹ́ bí olùdámọ̀ràn ọba, alákòóso ìṣèjọba àti àwọn olórí ogun pàtàkì. Ìpò wọ̀nyí fi hàn pé àwọn obìnrin ní ipa gidigidi nínú ètò ìṣàkóso ìlú, èyí sì tako àgbékalẹ̀ tí àwọn ìjọba amúnisìn fi lọ́lẹ̀ nípa pé àwọn obìnrin Adúláwọ̀ kì í lẹ́nu nínú ìkópa nínú ètò ìṣèlú (Amadiume, 1997).

Ní apákan ààrín gbùngbùn Adúláwọ̀, pàápàá láàrin àwọn ẹ̀yà Bakongo, àwọn obìnrin ní agbára ìṣèlú àti ajẹmọ́ ẹ̀mí. Wọ́n lè jẹ́ olórí ìdílé, agbátẹ̀rù nínú àṣà ìbọ̀rìṣà àti alárinà láàrin àwọn alàáyè àti ayé àwọn bàbá-ńlá wọn. Nínú irúfẹ́ àwọn àwùjọ báyìí, ìtẹ́wọ́gbà ètò ìṣèlú máa ń bá agbára ẹ̀mí lọ pẹ̀lú ara rẹ̀,

èyí tí ń jẹ́ kí àwọn obìnrin lè ní ipa nínú ìṣàkóso nípasẹ̀ ìtọ́sọ́nà ìwà rere àti ìtọ́jú ìlànà àgbáyé. (Amadiume, 1997). Ojúṣe yìí jọra pẹ̀lú ètò ìṣèlú ilẹ̀ Yorùbá, níbi àwọn obìnrin ti jẹ́ agbátẹrù ní ìdí ẹ̀sìn.

Ní Ìlà-Oòrùn Adúláwọ̀, a tún rí ipa obìnrin nínú ètò ìṣàkóso. Láàrin àwọn ẹ̀yà àwọn Buganda, àwọn ìyá ọba àti àwọn obìnrin ilé ọba máa ń kó ipa nínú ètò ìṣèlú ààfin, ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn ẹ̀yà mìíràn àti ìpinnu ẹni tí yóò gorí ìtẹ́. Èyí fi hàn pé àwọn obìnrin lẹ́nu nínú yíyan ọmọ-oyè gẹ́gẹ́ ìjòyè afọbajẹ.

Ní orílẹ̀-èdè Ethiopia, àwọn obìnrin ilé ọba àti àwọn obìnrin ọlọ́lá ní agbára gẹ́gẹ́ bí alábòójútó ìjọba, olùmọ̀ràn àti òǹnilẹ̀, wọ́n ń kó ipa nínú ìṣàkóso orílẹ̀-èdè ní ọ̀pọ̀ ìgbà nínú ìtàn wọn. Èyí yàtọ̀ díẹ̀ sí ètò ìṣèlú ti ilẹ̀ Yorùbá, èyí tún ṣàlàyé sí i pé, ìṣèlú àwọn obìnrin Adúláwọ̀ jẹ́ èyí tí ó bá òfin mu nínú ìtàn.

Ohun tí ó mú ìyàtọ̀ bá ipò ìṣàkóso àwọn obìnrin Yorùbá yàtọ̀ èyí, pàápàá jùlọ, nípasẹ̀ ipò Ìyálóde, ni bí wọ́n ṣe ya ipò agbára obìnrin sílẹ̀ sọ́tọ̀ nínú ètò ìṣàkóso tí ó dá lórí ìgbìmọ̀ àti ìfikùnlukùn. Nínú ètò yìí, agbára kì í kó jọ sí ọwọ́ ọ̀wọ́ àwọn ènìyàn kan ṣoṣo, ṣùgbọ́n ó máa ń pínpín láàrin ọ̀pọ̀ ikò àwọn aládarí. Èyí jẹ́ kí àwọn adárí àwọn obìnrin lè kópa tààrà nínú ìfikùnlukùn ìṣèlú àti ìpẹ̀tù-sááwọ̀.

Nípa fífi ìṣàkóso obìnrin ní Yorùbá wé àwọn ilẹ̀ Adúláwọ̀ mìíràn, ìwádìí yìí fi hàn pé ó yẹ kí a máa túmọ̀ agbára òṣèlú obìnrin Adúláwọ̀ bí ó ṣe jẹ mọ́ àṣà ìbílẹ̀ wọn, kì í ṣe lábẹ́ ìgbékalẹ̀ àti ìlànà ètò ìṣèjọba àwọn amúnisin tàbí Aláwọ̀-funfun. Nínú àfíwé yìí, ipò Ìyálóde fara hàn gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára àwọn òpó tí ó péye jù lọ nínú ìṣàkóso obìnrin ní ilẹ̀ Adúláwọ̀.

Ní ìparí, gbogbo àwọn àpẹẹrẹ wọ̀nyí jọ fi hàn pé ìṣàkóso obìnrin jẹ́ apá kan tí ó wọ́pọ̀ nínú ètò ìṣàkóso Adúláwọ̀. Ọ̀pọ̀ ètò ìṣàkóso ìbílẹ̀ ti fi agbára obìnrin sínú àwọn ilé-ìgbìmọ̀ tí àṣà dá kalẹ̀, tí wọ́n sì máa ń ṣètò ìgbésí-ayé ọrọ̀ ajé, mú ìlànà àwùjọ dúró, àti dáàbò bo ìdájọ́ òṣèlú. Ní fífi Ìyálóde sínú àyíká àfíwé gbogbo Adúláwọ̀ yìí, a lè rí i pé ipò ìṣàkóso obìnrin Yorùbá jẹ́ apá kan nínú àṣà ìṣàkóso Adúláwọ̀ tó gbòòrò, tí ó dá lórí ìbáṣepọ̀, ìwà rere, àti ìtẹ̀síwájú ipò láti ìran dé ìran. Ní fífi ipò ìdarí obìnrin Yorùbá wé àwọn àpẹẹrẹ tí a rí nínú àwọn àwùjọ Adúláwọ̀ mìíràn, ìwádìí yìí fi hàn pé ó ṣe pàtàkì láti ṣe àlàyé ìtúmọ̀ agbára ìṣèlú àwọn obìnrin ilẹ̀ Adúláwọ̀ láti inú òye àti àṣà ìbílẹ̀ wọn, kì í ṣe lábẹ́ èrò tàbí àfihàn tí àwọn amúnisin àti àṣà Aláwọ̀-funfun gbé kalẹ̀. Nínú àfíwé yìí ni ipò Ìyálóde ti fara hàn gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ kan tí ó lágbára tí ó sì péye nípa nípa ipò ìdarí obìnrin ní àwùjọ Adúláwọ̀.

Ní àfikún, àwọn ìwádìí tuntun lára àwọn aṣègbèfábo Adúláwọ̀ ń tẹnu mọ́ pé ó ṣe pàtàkì láti dá àwọn àṣà ìdarí obìnrin ilẹ̀ Adúláwọ̀ padà. Wọ́n rí i gẹ́gẹ́ bí apákan nínú akitiyan láti yọ ìrònú àwùjọ kúrò nínú ìlapa ìmúnisin, kí àwùjọ sì ní ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ nípa ìṣàkóso, ìdájọ́ òdodo láàárín akọ̀nìyàn àti abonìyàn àti agbára ìmọ̀ ayé òde-òní (Tamale, 2020).

**Ìmọ̀ Ìtàn àti dída Agbára Obìnrin rú nípaṣẹ̀ Ìmúnisìn**

Ọ̀pọ̀ ìwádìí ti fi hàn pé ìjọba amúnisin ṣe àtúnṣe àwọn ipò ìṣàkóso ìṣèlú ní ilẹ̀ Adúláwọ̀ ní ọ̀nà tí ó gbà dín agbára àwọn obìnrin kù. Àwọn alákòóso ìjọba amúnisin tí wọ́n ń ṣiṣẹ́ lábẹ́ àfojúsùn akọlólorí àti ìjọba ajẹmọ́-orílẹ̀, sáábà máa ń ṣe àdáyanrí àwọn ìjòyè tí wọ́n jẹ́ ọkùnrin gẹ́gẹ́ bí aṣojú kan ṣoṣo nínú ètò ìṣèjọba ìbílẹ̀, nígbà tí wọ́n fi ọwọ́ rọ́ àwọn obìnrin sẹ́yìn. Ìtúnṣe bẹ́ẹ̀ kò yí ìṣàkóso padà nìkan, ó tún ní ipa lórí ìtàn, tí ó sì ṣe àkóbá fún ipò agbára àwọn obìnrin nínú ètò ìṣèjọba (Afigbo, 1972; Ranger, 1983). Ìmọ̀-ẹ̀kọ́ lẹ́yìn ìgbà ìmúnisin ti bẹ̀rẹ̀ síí tako àṣìṣe wọ̀nyí nípa mímú àwọn ètò ìṣèlú ìbílẹ̀ padà wá sí

inú ìmọ̀ àwùjọ nípa ìlo àṣà ìpohùn (oral tradition), ìwádìí àṣà ènìyàn (ethnography), àti ìtúpalẹ̀ ìmọ̀-obìnrin (feminist analysis) (Awe, 1992; Amadiume, 1997). Nínú ìyípadà ìtàn yìí, ìwádìí Yorùbá ti fi hàn pé ìdarí àwọn obìnrin tẹ̀ síwájú láìka ìfàsẹ́yìn ìmúnisin sí.

**Ìwòye Àwọn Aṣègbèfábo Ilẹ̀ Adúláwọ̀ lórí Takọ-tabo àti Agbára Ìṣèlú**

Ìwádìí àwọn onímọ̀-aṣègbèfábo Adúláwọ̀ ti kó ipa pàtàkì lórí òye nípa tako-tabo àti agbára ìṣèlú ní àwùjọ Adúláwọ̀. Dípò lílo ìlànà jẹ́ńdà Òyìnbó Aláwọ̀-funfun, àwọn onímọ̀ obìnrin Adúláwọ̀ tẹpẹlẹ mọ́ àyẹ̀wò agbára ní ìbámu pẹ̀lú àṣà àti ìtàn àwùjọ wọn. Oyewumi (1997) ṣe àlàyé pé àwọn ìjọba amúnisìn ìgbàlódé ìlànà àbùdá tako-tabo oníbejì ti Òyìnbó Aláwọ̀-funfun ṣe àfihàn lórí àwùjọ Yorùbá, èyí tí ó mú ìyípadà bá ìmọ̀ ìbílẹ̀ Yorùbá nípa agbára padà, torí ṣáájú ìgbà yẹn, agbára kì í ṣe nípa ìbálòpọ̀ ara, ṣùgbọ́n nípa ipò àwùjọ, ìbáṣepọ̀, àti àgbàlagbà.

Lábẹ́ àfojúsùn yìí, ipò ìṣàkóso Ìyálóde kì í ṣe ohun ìyàtọ̀ sí ìlànà agbára ọkùnrin, bí kò ṣe àbájáde tó bófin mu nínú ọgbọ́n ìṣèlú Yorùbá. Ojú-ìwòye àwọn aṣègbèfábo Adúláwọ̀ tẹnu mọ́ ọn pé a gbọ́dọ̀ lóye agbára àwọn obìnrin nínú ọgbọ́n ìbílẹ̀ tí ó mọ̀ pé ọ̀pọ̀ ọ̀nà ni a fi ń ní agbára, gẹ́gẹ́ bí ọjọ́-ori, ìdílé, ìwà rere, àti iṣẹ́ ìránṣẹ́ sí àwùjọ. Èyí ṣe pàtàkì gan-an láti lóye Ìyálóde gẹ́gẹ́ bí ipò ìṣèlú tí a ti dá sílẹ̀ nínú ètò ìṣàkóso, kì í ṣe gẹ́gẹ́ bí àfihàn tàbí ìrànlọ́wọ́ lasan (Ògúndípẹ̀-Leslie, 1994; Oyèwùmí, 1997).

Àwọn onímọ̀ bí Awẹ́ (1992) àti Amadiume (1997) sọ pé ìjọba amúnisin sáábà máa ń fi ẹ̀tọ́ ìṣèlú sí ọwọ́ olórí ọkùnrin nìkan, tí wọ́n sì dín agbára àwọn obìnrin kù. Ìlànà yìí kì í ṣe pé ó tún ètò ìṣàkóso ṣe nìkan, ó tún yí bí a ṣe kọ ìtàn padà, tí ó sì mú kí a má rí ipa agbára àwọn obìnrin nínú ìwé ìjọba. Nítorí náà, àwọn aṣègbèfábo Adúláwọ̀ kó ipa pàtàkì nínú mímú àwọn ipò-ìṣàkóso ìṣèlú àwọn obìnrin padà sí ìmọ̀ àti nínú didojú kọ́ ìpele ìmọ̀ tí ó ṣàkóso bí a ṣe ń dá ìmọ̀ sílẹ̀ nípa ilẹ̀ Adúláwọ̀.

**Ìṣèjọba Ìbílẹ̀ àti Agbára Ìmẹ̀tọ́**

Àbùdá pàtàkì nípa ìṣèjọba Yorùbá ni pé ó fi agbára ìmẹ̀tọ́ hàn gẹ́gẹ́ bí ìpìlẹ̀ ìmúlò agbára ìṣèlú. Peel (2000) sọ pé ìdarí nínú àwùjọ Yorùbá ráyè dá lórí ìwà tó péye, ìgbàgbọ́ àwùjọ, àti agbára láti mú ìbáṣepọ̀ àwùjọ bá a mọ́. Ìrètí ni pé agbára ìṣèlú máa ṣiṣẹ́ fún ìtẹ́lọ́run àwùjọ ju ìfẹ́ ara ẹni lọ, ó sì ń fi ọgbọ́n ìṣàkóso tí ó dá lórí ìdájọ́ àti ìbáṣepọ̀ hàn.

Nínú àfojúsùn ìwà rere yìí, Ìyálóde jẹ́ ipò àárín gbùngbùn gẹ́gẹ́ bí aṣojú ìṣèlú àti olùdájọ́ ìwà rere. Àwọn ojúṣe rẹ̀ kọja fífi ọ̀rọ̀ sọ́rọ̀ nìkan; ó ní ìpinnu láti ṣe ìpẹ̀tù-sáàwọ̀, ìmúlò ìṣọkan, àti ìtọ́jú àwọn àṣà àwùjọ. Nítorí náà, agbára Ìyálóde kò yàtọ̀ sí ìtẹ́wọ́gbà rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó ní ìwà rere, ó sì jẹ́ olórí pàtàkì nínú mímú agbára ìṣèlú tẹ̀ síwájú nínú ètò ìṣàkóso ìbílẹ̀. Ṣùgbọ́n, ìmúlò agbára ìwà rere àti ìdàgbàsókè ipò Ìyálóde yí padà gidigidi lábẹ́ ìjọba amúnisin, tí wọ́n tún ṣe àtúnṣe ìṣàkóso ìbílẹ̀ nípasẹ̀ ìmúlò agbára ní ẹ̀ka kan ṣoṣo àti ìjọba àtàwọn aṣojú pẹ̀lú, tí ó fi àwọn ọkùnrin sí àárín, tí wọ́n sì dín ipò ìṣàkóso àwọn obìnrin kù (Vaughan, 2000).

Ìfọkànsìn sí agbára ìwà rere yìí fi hàn ìtọ́kasí àtọkànwá ọgbọ́n ìṣèlú Yorùbá, tí ó sì tún ń dojú kọ́ àwọn àpẹẹrẹ ìwọ̀-oorùn tí ó yapa ìwà àti ìṣàkóso. Nípasẹ̀ fífi Ìyálóde sí àfojúsùn ìwà rere yìí, ìmọ̀-ẹ̀kọ́ tó wà ṣáájú fìdí rẹ̀ múlẹ̀ gẹ́gẹ́ bí àárín nínú ìṣèlú, tí ó sì ṣàfihàn pàtàkì ètò ìṣàkóso ìbílẹ̀ fún ìmúlò ìdarí àwọn obìnrin Adúláwọ̀ ní ìtàn àti lónìí.

**Ìlànà Ìwádìí**

Iṣẹ́ ìwádìí yìí ṣe àmúlò àṣà alohùn, ìrántí àṣà, ìwé ìtàn ọba àti agbára olórí nílé ọba àti ìṣe ìdarí lónìí nínú ètò ìṣàkóso Yorùbá. Lonà kejì, iṣẹ́ yìí tún lo ìmọ̀-ìtàn, ìwádìí ajẹmọ́-àṣà ènì àti ìmọ̀ aṣègbèfábo Adúláwọ̀ lórí ìṣèjọba ilẹ̀ Yorùbá, agbára ìṣèlú obìnrin, àti àwọn ìyípadà amúnisin sí ipò ètò ìṣèlú ìbílẹ̀ (Awe, 1992; Law, 1977; Oyewumi, 1997; Vaughan, 2000). Ọ̀nà àkójọ détà fún iṣẹ́ yìí níí ṣe pẹ̀lú ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò, èyí tí ó wáyé nípa ṣíṣe àṣàyàn abẹ́nà-ìmọ̀ tí a fi ṣe àwòta, tí ó tẹ̀lé àṣà nípa ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú òṣèlú ìbílẹ̀. Bákan iṣẹ́ yìí ṣe àmúlò aáyan àwọn ọ̀mọ̀ràn ìṣàjú, èyí tí ó wà nínú odidi ìwé, jọ́nà iṣẹ́ akadá, iṣẹ́ àpilẹ̀kọ, ìwé àtìgbàdégbà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Iṣẹ́ Ìwádìí yìí lo ìlànà ìtúpalẹ̀ asọpàtó àti aṣàlàyé tí ó dá lórí ìtàn, ìmọ̀-aṣègbèfábo Adúláwọ̀ àti ìmọ̀ ìbílẹ̀. Iṣẹ́ yìí tẹpẹlẹ mọ́ àfihàn agbára Ìyálódé, ó sì jẹ́ ìpèníjà fún àgbékalẹ̀ ètò ìṣèjọba tí ó tẹ̀lẹ́ ìlànà àwọn Aláwọ̀-funfun.

**Ibi tí Iṣẹ́ Iwádìí yìí Gbòòrò mọ**

Iṣẹ́ ìwádìí yìí dá lórí ipò Ìyálóde gẹ́gẹ́ bí ipò ìṣàkóso ní àwùjọ Yorùbá àti ilẹ̀ Adúláwọ̀ nìkan, èyí tí kò jẹ mọ́ ìṣèjọba àwọn obìnrin kọjá àyíká ilẹ̀ Adúláwọ̀. Ìtọ́kasí àwọn ìtàn òde-òní jẹ́ àfihàn ipò ìṣàkóso, kì í ṣe àfihàn gbogbo ìpinnu ìṣèlú obìnrin. Fún ìdí èyí, iṣẹ́ yìí fi àṣà àtẹnudẹ́nu àti orísun ìtumọ̀ (interpretive sources) ṣe àfihàn ètò ìṣàkóso ìbílẹ̀, èyí tí ó jẹ mọ́ agbára, ìlò agbára àti ìtànkálẹ̀ nípasẹ̀ ìṣe, ìrántí àti ìtẹ́wọ́gbà àwùjọ, dípò lílo ẹ̀rí láti inú àkọsílẹ̀ nìkan. A kò lo àwọn ọ̀nà ìtúpalẹ̀ ìṣèlú tó dá lórí ìmọ̀ asọ̀díye (quantitative) fún ìwádìí yìí, nítorí pé wọ́n lè yọ jíjẹ́ adárí obìnrin kúrò nínú ìmọ̀ àṣà, ìwà rere, àti ìbáṣepọ̀ àwùjọ.

**Ìyálóde gẹ́gẹ́ bí Ipò Ìṣàkóso**

Ìyálóde jẹ́ ipò ìṣèjọba àwọn obìnrin tí ó jẹ mọ́ àfihàn agbára àti ẹ̀tọ́ àwọn obìnrin nínú ètò ìṣèlú inú àwùjọ Yorùbá. Èyí kì í ṣe ipò ìmórúkọjẹ́ tàbí ipò àyẹ̀yẹ lasan, ó jẹ́ ipò ìṣèlú tí ó jẹ mọ́ àfihàn agbára àpapọ̀ àwọn obìnrin, ìwà rere wọn àti aṣojú wọn nínú ìṣàkóso àwùjọ. Ipò ìṣàkọ́ṣo yìí jẹ mọ́ àwọn ìtàn ìjọba amúnisin tí ó jẹ́ àpẹẹrẹ pé ìṣèlú ilẹ̀ Adúláwọ̀ jẹ́ ètò ìṣèlú akọlólorí. Láti fi Ìyálóde hàn gẹ́gẹ́ bí ipò ìṣàkóso obìnrin, ìtànkálẹ̀ rẹ̀ káàkiri ilẹ̀ Yorùbá, tí ó fi hàn bí ìdarí obìnrin ṣe di ipò ìṣàkóso ní agbègbè kọ̀ọ̀kan àti bí ó ṣe ń tẹ̀ síwájú láti ìgbà dé ìgbà (Muraina, Opẹyẹmi àti Ajímátanraẹjẹ, 2023).

Ní àwùjọ Yorùbá ṣáájú ìjọba amúnisin, ètò ìṣèjọba jẹ́ onípelejìpele, èyí tí ó bẹ̀rẹ̀ láti orí baálé ilé, baálẹ̀ àdúgbò, àwọn ìjòyè, àgbààgbà ìlú títí dé orí ipò ọba tí ó jẹ́ aláṣẹ ìlú. Agbára ìṣèlú pin sí ìpele-ìpele, dípò kó wà ní àárín gbùngbùn nìkan ṣoṣo, èyí sì gbára lé ìbáṣepọ̀, ọjọ́-orí àti ìwà rere. Nínú ìlànà yìí, àwọn obìnrin kò ta kété sí ètò ìṣèlú; dípò bẹ́ẹ̀, wọ́n fi ẹ̀tọ́ wọn sílẹ̀ nínú àwọn ipò ìṣàkóso, Ìyálóde sì ni olúborí àwọn ipò náà (Awe, 1992). Nínú ìtàn, Ìyálóde dúró gẹ́gẹ́ bí ipò tí ó gà jù lọ nínú ipò olórí àwọn obìnrin àti agbẹnusọ àwọn obìnrin nínú ètò ìṣèlú, ìdájọ́, àti ìgbáyégbádùn àwùjọ. Agbára rẹ̀ kì í ṣe agbára tí kò bá òfin mu, ó wà nínú oríṣiríṣi ìgbìmọ̀ ìṣèlú, ó sì máa ń kópa nínú ìṣèlú pẹ̀lú ọba àti àwọn ìjòyè tí wọ́n jẹ́ ọkùnrin (Fálọlá, 1999).

**Ìtumọ̀, Agbára àti Ìbófinmu Oyè Ìyálóde**

Orúkọ oyè Ìyálóde túmọ̀ sí àgbà, ìdarí, àti ìmúlò aṣẹ ìṣèlú. Nípa èdè àti àṣà, ó ṣe àfihàn agbára gíga jù lọ tí obìnrin ní nínú ètò ìṣàkóso Yorùbá. Agbára nínú àwùjọ Yorùbá kì í ṣe ti ìbálòpọ̀ ara tàbí àjogúnbá ìdílé nìkan; ó jẹ́ abajade àpapọ̀ ọjọ́-ori, ipò ìdílé, ìwà rere, àti iṣẹ́ fún àwùjọ. Nítorí náà, ìbófinmu agbára

Ìyálóde dá lórí ìwà ẹ̀tọ́ àti èrò báyéṣerí àwùjọ, kì í ṣe agbára àfipágbà (Oyewumi, 1997). Ìṣàkóṣo nínú ìlànà ìṣèlú Yorùbá jẹ́ àjọṣepọ̀ takọ-tabo, dípò ìfigagbága. Agbára máa ń wà nípasẹ̀ ìfarajìn, ìmẹ̀tọ́ àti ojúṣe ẹni láàrin àwùjọ. Ìyálóde jẹ́ ipò ìṣèlú àpapọ̀ àwọn obìnrin, èyí tí ó ń ṣe àfihàn ìfẹ́, àfojúsùn àti ẹ̀hónú wọn nínú ètò ìṣèjọba. Ipò yìí fi hàn pé oyè yìí jẹ́ aṣoju àti alàgàta láàrin àwọn obìnrin àti àwùjọ lápapọ̀, tí ó ní ojúṣe láti mú ìbáṣepọ̀ tó péye wà láàárín ìfẹ́ àwọn obìnrin àti ìdàgbàsókè àwùjọ. Agbára rẹ̀ ń gbèrú sí i nípasẹ̀ ìmọ̀ ẹ̀dá àwùjọ, ìtẹ́wọ́gbà àṣà àti ìkópa nínú ìgbékalẹ̀ òfin àti ìlànà àwùjọ (Muraina, Opẹyẹmi, & Ajímátanraẹ̀jẹ, 2023).

**Ipò àti Ojùṣe Oyè Ìyálóde**

Gẹ́gẹ́ bí ipò ìṣàkóso, Ìyálóde wà nínú ètò ìṣèlú Yorùbá gẹ́gẹ́ bí agbọn kan tí ó ṣe pàtàkì. Ó máa ń kópa nínú ìgbìmọ̀ àwọn olórí àti àgbààgbà, ó sì máa ń kópa nínú ìgbékalẹ̀ òfin àti ìlànà àbá ìṣàkóso, ìdájọ́ àti ìṣọkan àwùjọ (Fálọlá, 1999). Ojùṣe rẹ̀ kì í ṣe gẹ́gẹ́ bí aṣoju nìkan, ó tún jẹ́ agbẹnusọ fún àwọn obìnrin, olùlàjà àti alábòójútó ìmẹ̀tọ́ abo. Ìyálóde jẹ́ aṣoju nínú ètò ìṣèlú, èyí tí ó ń rii dájú pé ohùn àti ìpín àwọn obìnrin wà nínú àbá ìṣàkóṣo. Ipò aṣoju yìí ṣe pàtàkì nínú ètò ìṣèlú, ó jẹ́ okùnfà ìlọsíwájú, ìbáṣepọ̀ àti ìjíròrò nípa ọ̀rọ̀ àwùjọ. Ìyálóde jẹ́ alàgàta àti apẹ̀tù-sááwọ̀ ní àṣìkò ìtàpórógun láàrin àwùjọ àwùjọ, èyí lè jẹ́ aáwọ̀ láàrin obìnrin, ìdílé tàbí àwùjọ lápapọ̀. Ó jẹ mọ́ lílo agbára fún ìmẹ̀tọ́, ìjíròrò àti ìmúlò ìṣọkan.

Ìyálóde jẹ́ alákòóṣo ìmẹ̀tọ́. Ètò ìṣèlú Yorùbá jẹ́ mọ́ ìṣàkóṣo pẹ̀lú ìmẹ̀tọ́, Ìyálóde sì ni ó máa ṣe àfihàn ìwà yìí pẹ̀lú òtítọ́, ìdájọ́ òdodo àti ojúṣe ẹ̀dá láàrin àwùjọ. Ojúṣe rẹ̀ jẹ mọ́ ìtọkasi agbára nínú ètò ìṣàkóso obìnrin àti àwùjọ kan pàtó, tí ó ń ṣe ìtẹ̀numọ́ ìṣùwà-yanjú-ìṣòro àti ìtọ́jú àwùjọ (Muraina, Opẹyẹmi & Ajímátanraẹ̀jẹ). Ní àfikún, Ìyálóde jẹ́ àká ìmọ̀ àṣà àwùjọ, èyí tí ó máa ń ṣe ìtànkálẹ̀ àti àtagbà ẹ̀kọ́ ìjádarí, ìmẹ̀tọ́ àwùjọ àti àṣà ìṣèlú. Ipò yìí jẹ́ àfihàn agbára obìnnrin nínú ètò ìṣèlú ìbílẹ̀.

**Ipò Ìyálóde nínú Ìhun Ètò Ìṣèlú Yorùbá**

Ipò Ìyálóde nínú ìhun ètò ìṣèlú Yorùbá fi àpẹẹrẹ ètò ìṣejọba ìbílẹ̀ hàn, èyí tí ó jẹ mọ́ ìṣedéédé, ìṣejọba tẹrú-tọmọ àti ìkún-ara-ẹni-lọ́wọ́. Kì í ṣe ipò tí ó lòdì sí ìdarí ọkùnrin. Wíwà tí Ìyálóde wà nínú àwọn ìgbimọ̀ òṣelú jẹ́ àpẹẹrẹ ìdámọ̀ àwọn obìnrin nínú ètò ìṣèlú. Èyí ni pé wọn kì í ṣe àjèjì nínú ètò ìṣejọba àti ìṣàkóso (Fálọlá, 1999).

Ipò yìí tún ṣe àfihàn èrò àwùjọ Yorùbá tí ó fi ìdarí sí ohun àpapọ̀ àti tí a lè jíròrò lé. Ìmúlò agbára nínú ètò yìí ń fara hàn nípasẹ̀ ìmọ̀ àwùjọ, ìwà rere, àti agbára láti ṣètò ìṣọkan àwùjọ. Ipò Ìyálóde gẹ́gẹ́ bí ipò-ìṣàkóso ṣe fi ojúṣe àti ìdarí tó dá lórí ìwà hàn, dípò fífi ìtẹ̀síwájú agbára ṣe àkóso, tí ó sì tẹnu mọ́ ìbáṣepọ̀ àwùjọ àti ìtọ́jú ìwà rere.

**Ìyálóde nínú Ètò Ìṣèlú Yorùbá Ṣáájú Ìmúnisin**

Ìṣàkóso Yorùbá ṣáájú ìjọba amúnisin jẹ́ mọ́ mọ́ onípele-ìpele níbi èyí tí ipò ọba ti wà ní àárin gbùngbùn ètò ìṣèjọba. Àwọn mìíràn tí wọ́n tún ní agbára nínú ètò ìṣejọba ni baálé ilé, baálẹ̀ àdúgbò àti àwọn olóyè. Gbogbo àwọn wọ̀nyí ni wọ́n ni ipa nínú ètò ìṣàkóṣo àwùjọ. Ètò ìṣèjọba wọn kì í ṣe ètò ìjọba àárin gbùgbùn nìkan (Peel, 2000). Nínú ìlànà ètò ìṣèlú yìí, Ìyálóde wà ní ipò ìṣàkóso tí ó fojú hànde, ó sì máa ń kópa nínú ètò ìgbìmọ̀ ìlú àti ìpinnu ṣíṣe, ìdájọ́ àti ìwàníṣọ̀kan (Muraina, Ọpẹ́yẹmí, & Ajímátanraẹ̀jẹ).

Nínú ètò ìṣèjọba Ọyọ́, èyí tí ó jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ètò ìṣèjọba Yorùbá tí ó ga jù lọ, Ìyálóde ń kópa nínú ètò ìṣèjọba àti ìjánu àwùjọ pẹ̀lú Aláàfin, Ọyọ́mèsì àti àwọn olóyè tí wọ́n ṣe pàtàkì mìíràn láàrin ìlú. Ìtàn fi hàn pé wọ́n máa kan sí Ìyálóde lórí ọ̀rọ̀ tí ó bá kan àwọn obìnrin nípa ètò ọrọ̀-ajé, ìjánu àwùjọ àti ìgbáyegbádùn àwùjọ. Èyí fi hàn pé ó jẹ́ aṣoju àwọn obìnrin nínú ìṣèlú àti agbára ìmẹ́tọ̀ (Law, 1977; Awe, 1992). Wíwà oyè Ìyálóde nínú ètò ìṣèlú onípele-ìpele yìí fi hàn pé ìdarí obìnrin kì í ṣe fun òfegè lásán, ó wà nínú ìfilọ́lẹ̀ ìlànà ìṣèjọba ni.

**Oníríuurú Agbègbè àti Ìdógba Oyè Jíjẹ**

Bó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn oyè, ayẹyẹ ṣíṣe àti ojúṣe kan pàtó ṣo mọ́ oyè Ìyálóde káàkiri agbègbè ní ilẹ̀ Yorùbá, bákan náà ni ìlànà àti ète ìṣàkóṣo wọn. Ní agbègbè Ìjẹ̀ṣà àti Ìjẹ̀bú, àwọn obìnrin ní àwọn oyè lọ́kan-ò-jọ̀kan, èyí tí ó fi wọ́n hàn gẹ́gẹ́ bí alàgàta láàrin ẹgbẹ́ àwọn obìnrin àti àjọ òṣèlú. Àwọn adarí wọ̀nyí ń kópa nínú ìpẹ̀tù-sááwọ̀, ààtò ọjà, ìṣèlú àwọn ohun ajẹmétùtù àti gbígbé òfin ìmẹ̀tọ́ ró. Èyí ṣe àfihàn ìlọ́wọ́sí àwọn obìnrin nínú ètò ìṣèlú (Bascom, 1969; Fálọlá, 1999).

Ní agbègbè Ẹ̀gbá, agbára ìṣèlú àwọn obìnrin fara hàn nínú ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àti ìjíròrò wọn pẹ̀lú àwọn ọkùnrin tí wọ́n jẹ́ olóyè ìlú, pàápàá jù lọ nínú àwọn ọ̀rọ̀ tí ó bá kan ìṣòwò, owó-orí àti ìṣètọ̀ láàrin àwùjọ. Àwọn onímọ̀ gbà pé agbára yìí ti wà láti ìgbà pípẹ́ pẹ̀lú ipò Ìyálóde, èyí tí ó jẹ́ okùnfà ìṣewẹ́kú ìlo agbára àṣẹ àti ààtò ìṣèjọba (Mba, 1982; Vaughan, 2000). Àpẹẹrẹ agbègbè yìí fi hàn pé ìdarí obìnrin káàkiri Ilẹ̀ Yorùbá jẹ́ ipò ìṣàkóso tí ó hànde sí ọ̀pọ̀ ènìyàn, èyí tí kì í ṣe ohun tí ó ṣèèsì tàbí ìṣẹ̀lẹ̀ ìdákúrekú.

**Ìdàrúdàpọ̀ Ìmúnisin àti Pípa Ipò Ìyálóde rẹ́ mnínú Ìtàn**

Ìjọba amúnisin tún ṣe ìdàrúdàpọ̀ lórí ètò ìṣèlú Yorùbá nípasẹ̀ fífi ètò ìṣèjọba àwọn aláwọ̀-funfun jẹ gàba lé e lórí, nípa ṣiṣe àgbékalẹ̀ àwùjọ gẹ́gẹ́ bí pé àwọn ọkùnrin nìkan ni ó ń ṣe àkóṣo ìlú. Wọ́n yọwọ́ àwọn obìnrin kúrò nínú ètò ìṣèlú lábẹ́ ètò ìṣejọba ilẹ̀ gẹ̀ẹ́sì (Afigbo, 1972; Ranger, 1983). Ìyọkúrò àwọn obìnrin nínú ètò ìṣèlú yìí jẹ́ okùnfà fún àìsí orúkọ àwọn obìnrin nínú àká àwọn amúnisìn gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó ní ẹ̀tọ́ àti ipa nínú ètò àwùjọ. Síbẹ̀, ìdínà amúnisin kò túmọ̀ sí pípa ipò Ìyálóde rẹ́ kúrò nínú àṣà alohùn àwùjọ Yorùbá.

**Ìtẹ̀síwájú àti Ìmúlò Oyè Ìyálóde ní Òde-Òní**

Wíwà tí oyè Ìyálóde nínú ètò ìṣèjọba káàkiri Ilẹ̀ Yorùbá ṣe àfihàn orírun agbára ìṣèlú tí obìnrin ní nínú ètò ìṣèlú, èyí tí ó ṣe okùnfà wíwà tí ó wà láàrin àwùjọ di òní yìí. Lóde òní, àṣẹ̀ṣẹ̀dé gẹ́gẹ́ bí ìlànà ìdarí àwọn obìnrin; dípò bẹ́ẹ̀, ó jẹ́ ipò ìṣàkóso tó dá lórí ọgbọ́n ìṣèlú ìbílẹ̀ àti ìtàn ìpìlẹ̀ nípa ìkópa àwọn obìnrin nínú ètò ìṣèlú. Nípasẹ̀ àgbéyẹ̀wò orígun ìtẹ̀síwájú yìí, ìwádìí fi hàn pé àwọn olóyè Ìyálóde lónìí ti ń ṣe àkóso láti ọ̀pọ̀ ọ̀rúndún sẹ́yìn, wọ́n sì ń kó ipa àti ojúṣe wọ́n nínú ìjíròrò nípa ọ̀rọ̀ ìlú.

Ìmọ̀ ìtàn nípa oyè Ìyálóde gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan nínú adárí nínú ètò ìṣèlú tún yí ìtàn nípa àwọn obìnrin nínú ètò ìṣèlú Áfíríkà padà. Dípò rírí àwọn obìnrin gẹ́gẹ́ ní ipò adarí gẹ́gẹ́ bí ohun àìbẹ́gbẹ́mu tàbí ipò tó mòòkùn, àkọọ̀lẹ̀ ìtàn fi hàn pé ipò àwọn obìnrin gẹ́gẹ́ bí adarí ń tẹ̀ síwájú gẹ́gẹ́ bí ipò ìṣàkóso tí ó wà ṣáájú ìmúnisin, tí ó sì tún ń gbòòrò síi ní òde-òní. Èyí lọ ní ìbámu pẹ̀lú ìlépa àwọn aṣègbèfábo Áfíríkà, èyí tí wọ́n ń pè fún kí ìpadàbọ̀sípò bá ipò agbára àwọn obìnrin nínú èto ìṣèlú àarin gbùngbùn, kí ó mà dàbí ohun tí ó ṣàjèjì (Amadiume, 1997; Ògúndípẹ̀-Leslie, 1994).

**Ipa rẹ̀ lórí Ìtàn Obìnrin Ilẹ̀ Áfíríkà nínú Ètò Ìṣèlú**

Gbígbé Ìyálóde kalẹ̀ nínú ìtàn ètò ìṣèlú káàkiri Ilẹ̀ Yorùbá kó ipa ńlá lórí ìṣàtakò ìmúnisìn nínú ìtàn ètò ìṣèlú ilẹ̀ Áfíríkà, ó sì mú agbára ìṣèlú àwọn obìnrin ní àwùjọ Yorùbá padà bọ̀ sípò. Ó fi hàn pé àwọn obìnrin ilẹ̀ Áfíríkà jẹ́ aṣáájú nínú ètò ìṣèjọba, ìlo agbára lọ́nà tí ó tọ́ àti gẹ́gẹ́ bí adárí tí ìjádarí rẹ̀ mú àtúnṣe bá ìlànà ìṣàkóso ìṣèlú láti ọ̀pọ̀ ọ̀rúndún sẹ́yìn. Nítorí náà, ìtàn Ìyálóde jẹ́ ìtàn nípa ìpìlẹ̀ adarí nínú ìtàn ìṣèlú ilẹ̀ Áfíríkà, èyí tí ó jẹ́ àwòkọ́ṣe nínú ìmúgbòòrò, àkóyawọ́ àti ojúṣe láàrin àwùjọ.

Nípasẹ̀ ìpadàbọ̀sípò àti ìtẹ̀síwájú ìtàn wọ̀nyí nínú ìwádìí yìí, abala yìí tún jẹ́ kó hàn pé Ìyálóde jẹ́ ipò ìṣàkóso tí ó ti péye nínú ìlànà ìṣàkóṣo àwọn obìnrin Adúláwọ̀, èyí tí ó sì jẹ́ àfihàn ìgboyà obìnrin Adúláwọ̀, ìfarajìn fún àwùjọ, ìlànà títọ́ àti òmìnira àṣà.

Rírí Ìyálóde gẹ́gẹ́ bí ipò ìṣàkóso ìdarí fi ìrònújinlẹ̀ hàn nípa ìtumọ̀ ìjákọni ní ilẹ̀ Adúláwọ̀, èyí tí ó yàtọ̀ sí àwọn àfihàn ilẹ̀ Òyìnbó Aláwọ̀-funfun tí ó jẹ mọ́ ìdániyàsọ́tọ̀, agbára ogun jíjà tàbí àṣìkò ìdàrúdàpọ̀ ẹ̀ẹ̀kan ṣoṣo. Nínú ìlànà ìmọ̀ ilẹ̀ Adúláwọ̀, ìjákọni kì í ṣe nípa ìṣẹ́gun tàbí ìfihàn agbára, dípò bẹ́ẹ̀, ó jẹ́ ìlò agbára láti dáàbò bo àwùjọ nípa wíwà ní àlááfíà àti ìfilọ́lẹ̀ ìlànà ìwà rere láti ìran dé ìran (Achebe, 1984; Wiredu, 1996).

Ìyálóde jẹ́ ipò akọni nípasẹ̀ ìtẹ̀síwájú ipò ìṣàkóso àti ìfilọ́lẹ̀ ìlànà ìwà rere. Agbára rẹ̀ máa hàn nípasẹ̀ jíjẹ́ aṣojú, olùlàjà àti adarí pẹ̀lú ọgbọ́n inú àti ìwà rere, kì í ṣe nípasẹ̀ ìlò ipá. Èyí jẹ́ kí ó hàn pé ìjákọni kì í ṣe ohun tí ó ṣo mọ́ ìtàn ẹni tí ó wà ní ipò, ó wà nínú ìtẹ̀síwájú ipò náà gan-an fúnra rẹ̀, èyí sì máa ń hàn nínú ìgbọ́kànlé àwùjọ, ìtẹ́wọ́gbà gbogbo ènìyàn àti ìtẹ̀síwájú nínú ètò ìṣèlú. Ìtẹ̀síwájú ipò Ìyálóde fún ọ̀pọ̀ ọ̀rúndún jẹ́ àfihàn agbára ìṣèlú tí ó yẹ ní rírí gẹ́gẹ́ bí ògidì ipò akọni.

Iṣẹ́ yìí tún ṣe àfihàn àwọn ìlànà ìtàn Òyìnbó Aláwọ̀-funfun tí wọ́n rí ìjákọni gẹ́gẹ́ bí ìfarahàn ìdìtẹ̀, ìfẹ̀hónúhàn tàbí ìlànà ìdarí ẹ̀dá kan pàtó. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ìtàn bẹ́ẹ̀ wúlò, wọ́n kò fi gbogbo ìtàn ìṣèlú ilẹ̀ Adúláwọ̀ hàn. Nínú àṣà ìṣèlú Yorùbá, wọ́n máa ń wo ìdarí gẹ́gẹ́ bí ojúṣe láti dáàbò bo àwùjọ, èyí tí ó jẹ mọ́ ìlò agbára nípasẹ̀ ìwà rere, ìtẹ̀síwájú àti ìfarajìn àwùjọ, dípò àṣìlò agbára (Peel, 2000). Ìyálóde jẹ́ àpẹẹrẹ tí ó fojú hànde, gẹ́gẹ́ bí alákòóyawọ̀ àti ìṣọ̀kan nínú ètò ìjọba.

Láti ojú ìwòye ìmọ̀ aṣègbèfábo Adúláwọ̀, fífi Ìyálóde hàn gẹ́gẹ́ bí akọni nínú ipò ìṣàkóso ń mú àtúnṣe bá àwọn ìrònú tó fara-pamọ́ nínú ìtàn àwọn amúnisin àti ìtàn ìṣáájú. Nípasẹ̀ ṣíṣo agbára ìṣèlú mọ́ agbára ọkùnrin nìkan. Ọ̀pọ̀ ìtàn ti sọ nípa bí ìṣàkóṣo àwọn obìnrin ṣe jẹ́ ohun tí wọn kò fi sí ààrín ìtàn àwùjọ, ṣùgbọ́n fífi Ìyálóde sí ààrín ìtàn tún fi agbára obìnrin sí ipò tí ó yẹ kí ó wà nínú ìtàn ìṣèlú, èyí sì jẹ́ kí ó hàn pé ìjákọni àwọn obìnrin Adúláwọ̀ jẹ́ ohun tí ó ní ìpìlẹ̀ nínú ètò ìṣèlú, èyí tí kì í ṣe ohun tí kò wọ́pọ̀ (Amadiume, 1997; Nzegwu, 2006).

Ní ọ̀gangan-ipò jíjẹ́ akọnikùnrin àti akọnibìnrin ní ilẹ̀ Adúláwọ̀, Ìyálóde jẹ́ àpẹẹrẹ akọni tí ó dá lórí ìtẹ̀síwájú, ojúṣe ìwà àti ìmójútó àṣà ìbílẹ̀. Irúfẹ́ ìmọ̀ yìí rí ìjákọni ní ipò ìṣàkóso gẹ́gẹ́ bí ohun tí ó ṣo mọ́ ìgbé-ayé ẹ̀dá ní àwùjọ. Èyí sì t fi hàn pé ìlànà ìṣèjọba ìbílẹ̀ jẹ́ orísun pàtàkì ìmọ̀ ìṣèlú àti ìwà rere, kì í ṣe fún ilẹ̀ Adúláwọ̀ nìkan, ṣùgbọ́n fún ìmọ̀ àgbáyé pẹ̀lú.

**Àfiwé Èrò nípa Ìyálóde káàkiri Ilẹ̀ Yorùbá**

Káàkiri Ilẹ̀ Yorùbá, ipò Ìyálóde jẹ mọ́ ìlànà ìtàn ìbílẹ̀, ó sì tún ṣo mọ́ ìmọ̀lára nípa ìdarí àwọn obìnrin, agbára ìwà rere, àti ìdarí ipò ìṣàkóso tí ó jẹ mọ́ àjọṣe. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àpèlé Ìyálóde wà ní ọ̀pọ̀ ìlú Yorùbá, ipa rẹ̀, àjọṣe rẹ̀ pẹ̀lú agbára ọkùnrin àti bí a ṣe ń lo ó yàtọ̀ láti ìlú kan sí òmíràn gẹ́gẹ́ bí àtúnṣe ìṣèlú agbègbè, ìṣàkóso ọrọ̀ ajé àti ìtàn ìṣẹ̀lẹ̀. Ìwádìí nipa àfiwé ipò Ìyálóde káàkiri Ilẹ̀ Yorùbá fi hàn pé ìtẹ̀síwájú wà nípa ìtẹ̀síwájú ìdarí obìnrin àti ìyàtọ̀ nípa bí wọ́n ṣe ń ṣàkóso ìjọba (Muraina, Ọpẹ́yẹmí, & Ajímátanraẹ̀jẹ).

**Ìyálóde ní Ìlú Ọyọ́ àti Àwọn Ilú tí ó ṣo mọ́ Ọyọ́**

Nínú ètò Ìjọba ìlú Ọyọ́ àti àwọn ìlú tí ó ṣo mọ́ Ọyọ́, Ìyálóde wà nínú ipò ìṣàkóṣo ètò ìṣèlú tí ó ga. Ìtàn fi hàn pé Ìyálóde Ọyọ́ jẹ́ ẹni tí wọ́n mọ̀ gẹ́gẹ́ bí apá kan pàtàkì nínú ìṣèlú, tí ó sì ní ipa lórí ọ̀rọ̀ obìnrin, ìṣòwò àti ìmúdúró vàwùjọ (Law, 1977; Awe, 1992). Nínú ètò ìṣèlú Ọyọ́, èyí tí ó jẹ mọ; àwọn ìgbìmọ̀ àti ìṣàkóso àárín gbùngbùn, ààyè wà fún ọkùnrin àti obìnrin jínú ètò ìṣàkóṣo. Nínú ìlànà yìí, ojúṣe Ìyálóde ni bí àṣojú àwọn obìnrin àti ẹni tí ń lépa ìmúdúrò agbára ìwà rere nínú ètò ìṣèlú.

Ìtẹ̀síwájú ipò Ìyálóde ní àwọn ìlú tí ó tan mọ́ Ọyọ́ nípa èto ìṣèlú bí Ògbómọ̀ṣọ́, Òkè-Ògùn àti Ìbàràpá, Ẹdẹ àti àwọn ìlú mìíràn fi hàn pé àwọn ìlú wọ̀nyí ti gba àṣà fífi ààyè gba obìnrin gẹ́gẹ́ bí apákan tí ó ṣe pàtàkì nínú ètò ìṣèlú. Èyí sì jẹ́ kí Ìyálóde ní ipò pàtàkì nínú àjọ ìgbìmọ̀ àti alákòóṣo èto ìṣèjọba. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé agbára Ìyálóde gangan yàtọ̀ láti ìlú kan sí òmíràn, ojúṣe rẹ̀ dàbí aṣojú, olùlàjà àti alámòójútó ìwà rere (Fálọlá, 1999; Peel, 2000).

**Ìyálóde ní Agbègbè Ẹ̀gbá àti Ẹ̀gbádò**

Ní agbègbè Ẹ̀gbá àti Ẹ̀gbádò, ìdarí obìnrin sáábà máa ń jẹ mọ́ ètò ọrọ̀-ajé àti àjọṣepọ̀ ètò ìṣèlú. Ní àwọn agbègbè yìí, Ìyálóde jẹ́ olórí tí o ní ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn obìnrin oníṣòwò, àwọn ẹgbẹ́ ọlọ́jà àti ìtẹ̀síwájú àwùjọ. Ìwádìí ìtàn nipa ìjìjàgbara àwọn obìnrin Ẹ̀gbá fi hàn pé àwọn obìnrin ní agbára ìṣèlú pàtàkì nípasẹ̀ àwọn ìgbìmọ̀ ìṣàkóso tí wọ́n dá sílẹ̀, pàápàá ní ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn ìjòyè lọ́kùnrin àti àwọn alákòóso ìjọba amúnisin (Awẹ́, 1992). Ní ọ̀gangan-ipò irúfẹ́ ìlànà yìí, Ìyálóde lo agbára rẹ̀ láti kó àwọn obìnrin jọ, èyí sì jẹ́ kí ó ṣeé ṣe fún un láti jẹ́ aṣojú tí ó ṣe pàtàkì nínú ètò ìṣèlú, dípò kí ó jẹ́ ipò ajẹmáyẹyẹ lásán. Ètò ìṣàkóṣo rẹ̀ fi hàn bí ìbáṣepọ̀ agbára ọrọ̀ ajé àti agbára ètò ìṣèlú ṣe rí nínú àṣà Yorùbá àti bí ètò ìṣàkóṣo àwọn obìnrin ṣe jẹ́ kí ó rọ́rùn láti mú ìtẹ̀síwájú àti ìgbòòrò bá ètò ìṣèjọba láti ìran dé ìran.

**Ìyálóde láàrin àwọn Ilú Ekó àti àwọn Ìlú Ńlá mìíràn ní ilẹ̀ Yorùbá**

Ní ìlú Èkó àti àwọn agbègbè rẹ̀, ipò Ìyálóde ti ṣe àtúnṣe sí àwọn àyípadà inú ètò ìṣèlú àti ọrọ̀ ajé, pàápàá júlọ, ní àṣìkò ìjọba amúnisin. Nígbà tí àwọn amúnisin ń ṣapá láti mú àdínkù agbára àwon obìnrin pẹ̀lú fífi agbára fún àwọn ọkùnrin nínú nìkan nínú ètò ìṣèlú, Ìyálóde ní àwọn agbègbè wọ̀nyí tẹ̀ síwájú láti ní ipa lórí ètò ìṣèlú nípasẹ̀ ẹgbẹ́ àwọn obìnrin, ètò ìṣàkóso ọjà àti ìfikùnlukùn, èyí tí kò ní àkọsílẹ̀ (Vaughan, 2000). Àwọn àtúnṣe wọ̀nyí fi agbára ìfarajìn Ìyálóde hàn. Ìyálóde ń lépa ìmúdúró ètò ìṣèlú nípasẹ̀ ọ̀nà ìṣàkóso tí ó dá lórí ìtẹ̀síwájú àwùjọ àti ìmúdúró ìwà rere. Irú ìfarajìn yìí fi hàn pé ìlànà ìṣàkóso yìí lè tẹ̀ síwájú pẹ̀lú gbogbo ìgbóguntì àwọn ìjọba amúnisìn tàbí àìṣedéédé tí ó ti ilẹ̀ òkèèrè wá (Muraina, Ọpẹ́yẹmí, & Ajímátanraẹ̀jẹ).

**Ipò Obìnrin nínú Ètò Ìṣèlú Agbègbè Òndó àti Ìjẹ̀ṣà**

Ní àwọn ìlú kan ní ìpínlẹ̀ Oǹdó àti Ọ̀sun, ipò Ìyálóde yàtọ̀ sí ti àwọn agbègbè ilẹ̀ Yorùbá yòókù. Ní ìlú Oǹdó àti Ilẹ̀ Olújì Oyè Lọ́bùn ni ipò obìnrin tí ó ga jù nínú ètò ìṣèlú, òun náà sì ní àwọn ìgbìmọ̀ gẹ́gẹ́ bí olóyè ni abẹ́ rẹ̀. Èyí túmọ̀ sí pé bí Ọba Òsemọ̀wé ti ìlú Oǹdó àti Ọba Jegun ìlú Ilẹ̀ Olújì ṣe ní ìgbìmọ̀ lábẹ́ ni Lọ́bùn ní àwọn ìlú wọ̀nyí náà ni. Òpó oyè lábẹ́ Jegun nínú ìlànà ìṣèlú Ilẹ̀ Olújì ni Ìwàrẹ̀fà, nígbà tí Lọ́bùn jẹ́ òpójì (Zulu 1994). Ìlànà oyè ọkùnrin àti obìnrin ní ìlú Oǹdó àti Ilẹ̀ Olújì lọ báyìí:

**Àtòjọ Ìpò: Lọ́bùn (Ọbábìnrin) àti Ọ̀sẹ̀mọ̀wé àti Jegun (Ọbakùnrin)**

| **Lọ́bùn (Ọbábìnrin)** | **Ọ̀sẹ̀mọ̀wé àti Jegun (Ọbakùnrin)** |
|---|---|
| 1. The High Chief (Àgbà Oyè) Lísà Lọ́bùn | The High Chief (Àgbà Oyè) Lísà |
| 2. The High Chief (Àgbà Oyè) Jòmù Lọ́bùn | The High Chief (Àgbà Oyè) Jòmù |
| 3. The High Chief (Àgbà Oyè) Ọ̀dọ̀fin Lọ́bùn | The High Chief (Àgbà Oyè) Ọ̀dọ̀fin |
| 4. The High Chief (Àgbà Oyè) Ọràńgún Lọ́bùn | The High Chief (Àgbà Oyè) Sàmà |
| 5. The High Chief (Àgbà Oyè) Sùpọ̀u Lọ́bùn | The High Chief (Àgbà Oyè) Odúnwò |
| 6. The High Chief (Àgbà Oyè) Sásẹ̀rẹ́ Lọ́bùn | The High Chief (Àgbà Oyè) Sásẹ̀rẹ́ |

Source: Olasupo, 2010: 145).

Bákan náà, ọbabìnrin ni wọ́n ń pe ipò olórí àwọn obìnrin tí ó ga jù ní ìlú Ìbòkun ní ìpínlẹ̀ Ọ̀sun, nígbà tí ọba ìlú gan-an dúró gẹ́gẹ́ bí Ọbakùnrin. Ọbakùnrin àti Ọbabìnrin ni wọ́n ni àwọn ìgbìmọ̀ olóyè tí wọ́n jẹ́ afọbajẹ ní abẹ́ ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn. (Olomola, Ajuwon àti Omotosho nínú Olasupo, Olugbemi àti Adeniran, 2012). Àwọn ìgbìmọ̀ olóyè lábẹ́ wọn ni:

**Àtòjọ: Afọ́bákùnrinjẹ àti Afọ́bábìnrinjẹ**

| **Afọ́bákùnrinjẹ** | **Afọ́bábìnrinjẹ** |
|---|---|
| Ọ̀dọ̀fin | Ọ̀dọ̀finbìnrin |
| Ẹjẹmu | Ẹjẹmubìnrin |
| Àrò | Àròbìnrin |
| Ọsọ́lọ̀ | Ọsọ́lọ̀bìnrin |
| Ṣàbà | Ṣàbàbìnrin |
| Sajuku | Sajukubìnrin |

Source: Olomola, Ajuwon àti Omotosho nínú Olasupo, Olugbemi àti Adeniran, 2012).

Ìlànà yìí náà fara pé ti ìlú Kajola Ìjẹ̀ṣà ní agbègbè Ìjẹ̀ṣà, èyí tí ipò obìnrin nínú ètò ìṣèlú náà òpó kan náà pẹ̀lú ipò àwọn obìnrin ní gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn ní ìsàlẹ̀ yìí (Olasupo àti Fayomi 2012):

**Àtòjọ: Ọbákùnrin àti Ọbábìnrin**

| Ọbákùnrin | Ọbábìnrin |
| --- | --- |
| Bàbá Òrìṣà | Yèyé Òrìṣà |
| Bàbá Ọdọ̀fin | Yèyé Ọdọ̀fin |
| Bàbá Àrò | Yèyé Àrò |
| Bàbá Alárò | Yèyé Sálárò |
| Bàbá Ẹjẹmọ | Yèyé Ẹjẹmọ |

Source: Olasupo àti Fayomi, 2012:17

Bí ó tilẹ̀ jẹ pé ààyè gba àwọn obìnrin nínú ìlànà ètò ìṣèlú àwọn ìlú wọ̀nyí, síbẹ̀, Ọbakùnrin náà sì ni olórí ìlú ṣùgbọ́n ipa ribiribi ni àwọn ọku`nrin ń kó nínú ètò ìṣàkóṣo ìlú.

**Ìjọra àti Ìyàtọ̀ Ipò Ìyálódé ní Agbègbè Kọ̀ọ̀kan**

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn agbègbè yàtọ̀, àwọn ìlànà pàtàkì kan so ipò Ìyálóde káàkiri Ilẹ̀ Yorùbá pọ̀. Ìyálóde lọ́pọ̀ ìgbà jẹ́ aṣojú àgbà fún obìnrin nínú ètò ìṣèlú tí ń tẹnu mọ́ àjọṣe ìpinnu àpapọ̀. Agbára rẹ̀ dá lórí ìtẹ̀síwájú, ìwà rere àti ìgbọ́kànlé àwùjọ. Ipò yìí ṣe àfihàn irú ìdarí tó tẹpẹlẹ mọ́ ìlàjà, àmújútó ìwà rere àti ìmúdúrò àwùjọ (Oyewumi, 1997; Wiredu, 1996).

Bákan náà, ètò ọrọ-ajé ìlú ní ipa lórí ìsọ̀kan àti ètò ìṣàkóṣo Ìyálóde. Ní àwọn ìlú kan, ipa rẹ̀ wà nípò ìgbìmò ìṣàkóṣo ìlú, èyí tí ó ń ṣiṣẹ́ nípasẹ̀ ìgbìmò àwon obìnrin àti ètò ọrọ̀ ajé. Ìyàtọ̀ wọ̀nyí kò túmọ̀ sí ìlòdìsí, ó jẹ́ àfihàn agbára ìṣàkóso ìbílẹ̀ tí ó kún fún onírúurú àfihàn agbára àwọn obìnrin (Muraina, Ọpẹ́yẹmí, & Ajímátanraẹ̀jẹ).

**Pàtàkì Ìmọ̀ nípa Ìṣàkóṣo àwọn Obìnrin nínú ètò Ìṣèlú Yorùbá**

Ṣíṣe àfiwé Ìyálóde káàkiri ilẹ̀ Yorùbá mú ìpèníjà wá fún àwọn ìtàn tí ó ń ṣe ìdarí obìnrin gẹ́gẹ́ bí ohun tí ó dúró déédé tàbí tí ó dá yàtọ̀. Dípò bẹ́ẹ̀, ó fi àṣà ìṣèlú tó jinlẹ̀ hàn níbi tí a ti fi agbára obìnrin sílẹ̀ nínú ètò tí ó lórí ìtẹ̀síwájú, tí ó mọ́ àyíká àti àjọṣe ìṣèlú àdápọ̀. Ìyálóde kì í ṣe ìṣẹ̀lẹ̀ ìtàn ẹ̀dá ènìyàn kan ṣoṣo; ó jẹ́ agbọn kan pàtàkì nínú ètò ìṣèlú Yorùbá, èyí tí ó fi àwọn obìnrin sí ipò pàtàkì ètò ìṣèlú. Ṣíṣe àfiwé yìí ṣe àfihàn pé ipò Ìyálóde jẹ́ ipò ìṣàkóso tí ó gbára lé ìtàn tí ó fojú hàn sí gbogbo àwùjọ, èyí tí ìtẹ̀síwájú àti àtúnṣe ń bá láti ìgbà dé ìgbà àti láti agbègbè dé agbègbè agbègbè.

**Àgbálọgbábọ̀**

Ìwádìí yìí ti fi hàn pé ipò Ìyálóde jẹ́ ọ̀kan lára àwọn àpẹẹrẹ ìfarajìn obìnrin Adúláwọ̀ tí ó dá lórí agbára ìpìlẹ̀, èyí tí ìgbòòrò sì ń bá láarin àwùjọ. Ìwádìí yìí kò ṣe àfihàn akọni gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ ẹnìkan, ìṣe àwọn kan tàbí ìja ogun, ṣùgbọ́n ó fi hàn pé àwùjọ Yorùbá ṣàlàyé akọni nípasẹ̀ ìṣàkóso ipò, agbára ìwà rere, àti ìtẹ̀síwájú láàárín ìran. Nínú àjọṣepọ̀ yìí, Ìyálóde fara hàn gẹ́gẹ́ akọni obìnrin tí àkókò rẹ̀ kì í ṣe láti inú ìtàn ìgbésí ayé ẹ̀dá kan pàtó ṣùgbọ́n láti inú ipa ìṣàkóso tí ó jẹ mọ́ àgbékalẹ̀ obìnrin nínú àwùjọ.

Àrífàyọ iṣẹ́ ìwádìí yìí ni pé ipò akọni ni ipò ìṣàkóṣo gẹ́gẹ́ bí Ìyálóde tàbí àwọn ipò mìíràn tí ó jẹ́ ipò aṣíwájú àwọn obìnrin wà ní ilẹ̀ Yorùbá, ojú akọnibìnrin ni sì lè fi wo obìnrin yòówù tí ó bá di ipò yìí mú. Jíjẹ́ akọni ní ipò yìí kì í ṣe pé ó wà pẹ̀lú ẹnìkan ṣoṣo ní ṣáà tí onítọ̀hún bá wà lórí ipò ni, bí ó ṣe pé ó rọ̀ mọ́ ipò, èyí tí ó jẹ pé gbogbo ẹni tí ó bá ti wà ní ipò náà ni ó gbé àbùdá akọni wọ̀. Èyí ni pé gẹ́gẹ́ bí àwùjọ ṣe ń fi ọ̀wọ̀ ìjákọni wọ gbogbo ẹni ó bá wà ní

ipò ọba láàrin ìlú náà ni àwùjọ ṣe gbọdọ̀ fi irúfẹ́ ọ̀wọ̀ ìjákọni náà wọ ẹnìkẹni tí ó bá wà lórí ipò Ìyálóde. Èyí kì í ṣe nípasẹ̀ àwòmọ́ agbára ẹ̀dá náà gan-an ní pàtó, bí kò ṣe àwòmọ́ agbára ipò tí ó wà. Èyí sì jẹ mọ́ ìlànà ìṣẹ̀nbáyé tí àwùjọ ti là kalẹ̀ ṣáájú kí àwọn Òyìnbó amunisìn tó wọ àwùjọ Adúláwò. Irúfẹ́ ipò ọ̀wọ̀ yìí ní láti jẹ́ àwòtà fún ipò tí ó yẹ kí àwọn obìnrin wà nínú ìlànà ètò ìṣèlú gbogbo ilẹ̀ Áfíríkà lápapọ̀.

**Ìwé Ìtọ́kasí**


Achebe, C. (1984). The Trouble with Nigeria. Nigeria: Heinemann Educational Books.

Ade Ajayi, J. F. (1966). *Christian Missions in Nigeria, 1841-1891: The Making of a New Elite*. Longmans.

Afigbo, A. E. (1972). *The Warrant Chiefs: Indirect Rule in Southeastern Nigeria, 1891-1929*. Longman.

Amadiume, I. (1997). *Re-inventing Africa: Matriarchy, religion and culture*. Zed Books.

Awe, B. (1992). *Nigerian women in historical perspective*. Sankore Publishers.

Bascom, W. (1969). *The Yoruba of southwestern Nigeria*. Holt, Rinehart and Winston.

Chilisa, B. (2012). *Indigenous research methodologies*. Sage Publications.

Falola, T. (1999). *Yoruba gurus: Indigenous production of knowledge in Africa*. Africa World Press.

Gyekye, K. (1997). *Tradition and Modernity: Philosophical Reflections on the African Experience*. Oxford University Press.

Kovach, M. (2009). *Indigenous methodologies: Characteristics, conversations, and contexts*. University of Toronto Press.

Law, R. (1977). *The Oyo Empire, c. 1600-c.1836: A West African imperialism in the era of the Atlantic slave trade*. Oxford University Press.

Mama, A. (2001). Challenging subjects: Gender and power in African contexts. *African Sociological Review, 5*(2), 63–73.

Mama, A. (1996). *Women's studies and studies of women in Africa during the 1990s*. CODESRIA.

Mba, N. E. (1982). *Nigerian Women Mobilized: Women's Political Activity in Southern Nigeria, 1900-1965*. University of California Press.

Mbembe, A. (2001). *On the postcolony*. University of California Press.

Nzegwu, N. (2006). *Family matters: Feminist concepts in African philosophy of culture*. SUNY Press.

Ọláṣùpọ̀ F. A. àti Fayomi, I. (2012). "Historical Epochs of Local Government Administration in Nigeria: Women and the Poor.' *Global Journal of Human Social Science: Arts and Humanities*, 12, (9)(1). Global Journals Inc., USA.

Ọláṣùpọ̀, F. A. (2010) "African Perspective on the Globalization of Gender: The African Perspective" *The Global Studies Journal,* 3(2). USA: Common Ground Publishing LLC. www.CommonGroundPublishing.com (Ed), Ibadan: Rex Charles Publication in association with Connel Publication.

Oyewumi, O. (1997). *The Invention of Women: Making an African sense of Western gender discourses*. University of Minnesota Press.

Peel, J. D. Y. (2000). *Religious encounter and the making of the Yoruba*. Indiana University Press.

Ranger, T. (1983). The invention of tradition in colonial Africa. In E. Hobsbawm & T. Ranger (Eds.), *The invention of tradition* (pp. 211–262). Cambridge University Press.

Smith, L. T. (1999). *Decolonizing methodologies: Research and indigenous peoples*. Zed Books.

Sudarkasa, N. (1986). The status of women in indigenous African societies. *Feminist Studies, 12*(1), 91–103.

Tuhiwai Smith, L. (2012). *Decolonizing methodologies* (2nd ed.). Zed Books.

Wiredu, K. (1996). *Cultural universals and particulars: An African perspective*. Indiana University Press.

Zulu, S. (1994). "Feminism in Psyche of African Womanhood." A paper presented at the first Conference on Women in Africa and the Africa diaspora. University of Nigeria Nsukka.

## Author's Bio

**Remi Alapo** is a scholar and cultural researcher whose work centers on Yoruba history, women's leadership, and African indigenous knowledge systems. Their research explores gender, spirituality, oral traditions, and the preservation of underrepresented African heroines whose cultural labor shapes intergenerational memory across Africa and the diaspora.

Recebido em: 03/2026
Aceito em: 30/07/2026

**Para citar este texto (ABNT):** ALAPO, Remi. Oyè ìyálóde: ipò akọnibìnrin nínú ètò ìṣèlú àwùjọ yorùbá. *Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras.* São Francisco do Conde (BA), vol.6, nº Especial II, p.232-248, agosto 2026.

**To cite this text (APA):** Alapo, Remi (august 2026). Oyè ìyálóde: ipò akọnibìnrin nínú ètò ìṣèlú àwùjọ yorùbá. *Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras.* São Francisco do Conde (BA), 6 (Special II): 232-248.